# ÀFIWÉ ÈTÒ ÒṢÈLÚ NÍNÚ FÍÌMÙ "AGOGO ÈÈWỌ̀" ÀTI ÌWÉ "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

**LÁTI OWÓ Ọ**

**AKINSOJI OLAMIDE ZAINAB**

**ÀKÀNPỌ̀ IṢẸ́: YORÙBÁ /SOCIAL STUDIES**

**NỌ́MBÀ ÌDÁNIMỌ̀: 18012307011**

**NÍ ÌBÁMU PẸ̀LÚ GBÍGBA ÌWÉ Ẹ̀RÍ (N. C. Ẹ) NIGERIA CERTIFICATE EDUCATION ILÉ Ẹ̀KỌ́ GÍGA TÍ OLÙKỌ́NI ÀGBÀ TAI-SOLARIN COLLEGE OF EDUCATION ÒMÙ-ÌJẸ̀BÚ, NÍ ÌPÍNLẸ̀ ÒGÙN**

**OṢÙ Ọ̀WÀRÀ 2021**

# ÌFỌWỌ́SÍ

Mo fi ọwọ́ si í pé **AKINSOJI OLAMIDE ZAINAB** ti ẹ̀ka Yorùbá àti Social studies (Yor /Sos) tí nọ́mbà ìdánımọ̀ rẹ̀ jẹ́ **18032307011** ti ilé ẹ̀kọ́ olùkọ́ni (Tai Solarin College of Education, Omu Ijebu) ni ó kọ iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí lábẹ́ àmójútó mi

______________________ ______________________

**Olùkọ́ C. O. Ọnanuga** **Déètì**

**Alábòójútó Iṣẹ́ Àkànṣe**

# **ÌJÚBÀ**

Mo fi iṣẹ́ àsekágbá yìí júbà Ọlọ́run Ọba

Mo júbà akọ́dá tó dá tiẹ̀ sórí ewé

Mo júbà aṣẹ̀dá, tó dá tiẹ̀ sílè pẹ̀pẹ̀

Ibà Ọlọ́run, Atẹ́rẹrẹ kárí ayé

Ọba tó ní gbogbo ọgbọ́n

Ọba tó ní gbogbo òye

Àrìíìrọ̀ àlá

Atófaratì má sojo

Akọ̀ má ti ìkà lẹ́yìn

Àpèkẹ́, Àṣàkẹ́

Ọba lónìí

Ọba lánàá

Ọba títí ayé

Elédùmarè ọba awímáyẹhùn

Ọba tó kà mí yẹ lórílẹ̀ alààyè

Kábíyèsí Elédùmarè

Tótó ìbàà

# ÌFIPERÍ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní òǹbíni kò tó òǹwoni. Mo fi ìwé yìí dá àwọn òbí mi lọ́lá MR&MRS AKINSOJI fún àdúrótì wọn láti ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ mi yìí títí dé ibi tí mo báa dé lónìí, mo gbà á ladura pé kí ọba àláwùrà jẹ́ kí isu ọmọ jiná fun yín jẹ (Àmín).

Bákan náà ni mo tún fi dá ọkọ mi, Àyànfẹ́ mi EZEKIEL YAKUB AFOLORUNSO lọ́lá fún àtìlẹ́yìn rẹ̀. Mo gbà á ladura pé iṣẹ́ rẹ̀ kò ní di ìṣẹ́. Ọlọ́run Ọba á jẹ́ kí á pẹ́ fún àrà wa (Àmín).

# **ÌDÚPẸ́**

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní bí a ṣeni lóore, ọpẹ́ làá dá, ẹni tí a ṣe lóore tí kò dúpẹ́, ó dà bí ọlọ́ṣà kọ́ni lẹ́ru lọ ni. Èyí ló mú mi dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run ọba Àjọkẹ́ ayé, ọba Àṣàkẹ́ ọ̀run. Ọba mi elétí gbáròyé fún àǹfààní tí ó fún mi nínú olanla rẹ̀ láti lè kẹ́sẹjárí nínú ẹ̀kọ́ mi, láìsí wàhálà tàbí ìdààmú kankan, gbogbo ọpẹ́ ti Ọlọ́run ni.

Bákan náà mo dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn òbí mi ti wọn se ọlọ́kọ̀ mi wá sáyé MR&MRS AKINSOJI Fún àdúrà wọn lórí mi tọ̀sán-tòru, fún àdúrótì àti àtìlẹ́yìn wọn, mo wá bẹ ọba àláwùrà pé kí ó bá mi lora èmí wọn, gbogbo ìgbà tí ẹ máa lò lórí ilẹ̀, ẹ kò ní fi ìnira àti àìsàn lò ó, kí ẹ jẹun ọmọ pé.

Bákan náà mo dúpẹ́ lọ́wọ́ ọkọ mi, Adé orí mi, Ẹni bí ọkàn mi, Tèmi nì kan YAKUB ADEKOYA ọmọ EZEKIEL fún àdúrótì, àtìlẹ́yìn ìmọ̀ràn tí ó ṣe pẹ̀lú mi lórí ẹ̀kọ́ mi láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé ibi tí mo ba dé lónìí, kí Ọba òkè jẹ́ kí á pé fún ara wa, kí ó fi ọmọ ìdùnnú sí ààrín wa.

Ṣíwájú si mo dúpẹ́ lọ́wọ́ olùkọ́ tí ó jẹ́ alámòójútó iṣẹ́ ìwádìí yìí tí orúkọ wọn ń jẹ́ Olùkọ́ C. O Onanuga fún ìmọ̀ràn àti ìtọ́sọ́nà pẹ̀lú àsìkò tí wọ́n ń fi sílè láti bá mi bójú tó iṣẹ́ ìwádìí yìí. Mo gbà á ladura pé àdáwọ́lé yín á máa yọrí sí rere, àwọn ọmọ yín náà á máa bá àánú pàdé, gbogbo ìgbà tí ẹ máa lò lórí ilẹ̀, ẹ ò ni fi àìsàn lò ó (Àmín).

Mo tún dúpẹ́ dúpẹ́ lọ́wọ́ olùkọ́ tí ó kù ní Ẹ̀ka Èdè Yorùbá, àwọn bíì; olórí Ẹ̀ka èdè Yorùbá Aya Oloyede, Ọ̀gbẹ́ni S. R Adeyemi, Olùkọ́ Agboola pàtàkì jùlọ Aya Akinbode H. O fún àdúrà, ìmọ̀ràn, ìtọ́sọ́nà àti àtìlẹ́yìn lórí iṣẹ́ ìwádìí yìí, àwọn ọmọ tiyín náà á máa bá àánú pàdé àti àwọn tí ó kù (Àmín).

Mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ ẹ̀gbọ́n ìyá mi RUQAYAT AFOLASHADE ALIMI fún àtìlẹ́yìn, ìmọ̀ràn àti àdúrótì wọn lórí ẹ̀kọ́ mi, mo dúpẹ́, Ẹyin náà á jèrè ọmọ yín.

Ọpẹ mi kò tí tán lai tí dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn akegbe mi fún àdúrótì wọn lórí ẹ̀kọ́ mi bẹ̀rẹ̀ latori ỌLÁLÙDÉ OLÚWARÁNTÍ, AWÓDEMÚRÌN YÉTÚNDÉ,OLUWABUKOLA ELIZABETH, Pàtàkì jùlọ OYEWOLE JOHN ADEBOLA àti AKEEM OLUWARANTI NIHMOTALAH fún àdúrótì yín àbọ̀ Ọlọ́run kò ní fi yín sílè.

## ÀKÓÓNÚ

**Ìfọwọ́sí**

**Ìfáàrà**

**Ìjúbà**

**Ìfiperí**

**Ìdúpẹ́**

**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**

**1.0 Ìfáàrà**

**1.1 Bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ sílẹ̀**

**1.2 Bí ìwé eré orí ìtàgé ṣe bẹ̀rẹ̀ àti ìdàgbàsókè rẹ̀**

**1.3 Bí ìdàgbàsókè ṣe bá eré orí ìtàgé Yorùbá**

**1.4 Àpẹẹrẹ ìwé àti òǹkọ̀wé eré oníse**

**ORÍ KEJÌ**

**2.0 Nípa fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**2.1 Àgbéyèwò ètò òsèlú inú fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**2.2 Kókó inú fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**2.3 Àhunpọ̀ ìtàn inú fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**2.4 Àpéjúwe àwọn ẹ̀dá ìtàn inú fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**ORÍ KẸTA**

**3.0 Nípa ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà**

**3.1 Àgbéyèwò ètò òsèlú inú Ẹfúnsetán Aníwúrà**

**3.2 Kókó inú ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà**

**3.3 Àhunpọ̀ ìtàn náà ní ṣókí**

**3.4 Àpéjúwe àwọn ẹ̀dá inú ìtàn inú ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà**

**ORÍ KẸRIN**

**4.0 Nípa ìlò èdè inú Ẹfúnsetán Aníwúrà**

**4.1 Àgbéyèwò àwọn ọnà èdè inú fíìmù Agogo Èèwọ̀**

**ORÍ KARÙN-ÚN**

**5.0 Àgbálọgbábọ̀**

**5.1 Àbá àti ìṣòro tí ó kojú oluwadi**

**5.2 Ìkádìí**

**5.3 ìwé Ìtọ́kasí**

# ORÍ KÍN-ÍN-NÍ

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

IṢẸ́ ÀPILẸ̀KỌ YÌÍ DÁ LÓRÍ "ÀGBÉYÈWÒ ÈTÒ ÒṢÈLÚ NÍNÚ FÍÌMÙ ÀGBÉLÉWÒ ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ ÀTI FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWÒ".

Orí kìn-ín-ní ise yìí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú akitiyan bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ sílè. Bákan náà ni a ó ṣe àpẹẹrẹ ìwé àti òǹkọ̀wé eré oníse lorisirisi.

Orí kejì isẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ni a ó ti mọ nípa fíìmù agogo èèwò. Bákan náà ni a ó ṣe àfihàn àwọn kókó inú fíìmù agogo èèwọ́ àti àhunpọ́ ìtàn inú fíìmù agogo èèwọ́, náà ní ṣókí. Orí kejì ń tẹ síwájú nínú ṣíṣe Àgbéyèwò àwọn ẹ̀dá ìtàn inú fíìmù agogo èèwọọ̀.

Orí kẹta iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yóò dá lórí eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà , nínú èyí ni a ó ti ṣe Àgbéyèwò ètò òsèlú inú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà.

Bákan náà ni àwọn kókó tí ó wà nínú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà, pẹ̀lú àhunpọ́ ìtàn náà ni ṣókí yóò wáyé, àti àgbéyèwò àwọn ẹ̀dá inú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà.

Orí kẹrin isẹ́ àpilẹ̀kọ ni a ó ti sọ nípa ìlò èdè inú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà àti àgbéyẹ̀wò àwọn ọnà èdè inú fíìmù àgbéléwò Agogo Èèwọ́. Bákan náà ni a ó ṣe àlàyé àti àpẹẹrẹ àwọn ìlò èdè inú ère oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà àti Agogo Èèwọ́.

Orí karùn-ún iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ní a ó ti ṣe àgbálọgbábọ́ àti àbá ohun ìṣòro tí ó kojú olùwádìí pẹ̀lú ìkáàdí lórí iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí àti àwọn ìwé Ìtọ́kasí.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ wí pé Ètò Òṣèlú jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì láàárín àwọn ọmọ ènìyàn àti àwọn ẹ̀dá mìíràn tí Ọlọ́run dá yálà Ẹranko, Ẹja inú omi, Ẹyẹ ojú ọ̀run ti o n fò, gbogbo àwọn ohun wọ̀nyí ni wọ́n ní ọ̀nà tí wọ́n ń gbà láti darí ara wọn gẹ́gẹ́ bí Ètò Òṣèlú.

Gẹ́gẹ́ bí ọmọ ènìyàn, èyí ló mú kí ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùnmí Ìshọ̀lá náà ṣe àgbékalẹ̀ eré oníse tí ó sì ṣe àpéjúwe ètò òsèlú láàárín àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó lo nínú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà. Bákan náà ni èyí rìi nínú fíìmù àgbéléwò Agogo Èèwọ̀ èyí tí ilé-isẹ́ ọ́jọ̀gbọ́n Tunde Kelani náà ṣe àgbékalẹ̀ rẹ́.

Nínú isẹ́ àpilẹ̀kọ yìí a ó ṣe àgbéyèwò Ètò Òṣèlú nínú ìwé eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà àti ère oníse Agogo Èèwọ́ ni iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí yóò dá lé lórí.

## 1.1 BÍ ÈDÈ YORÙBÁ ṢE DI KÍKỌ SÍLẸ̀

Bí ẹka Yorùbá tí ń tẹ síwájú ní onírúurú nǹkan ìpè nija tó sì yẹ fún ìwádìí ń yọjú síta. Ìtàn Yorùbá sọ fún ní pé Odùduwà tí apá ìlà Òòrùn wá sí Ilé-Ifẹ̀. Ṣùgbọ́n ṣáájú Odùduwà ń kọ? Àwọn wo ló wà ṣáájú Odùduwà ni Ilé-Ifẹ̀? Báwo ni ayé wọn ti rìi? Irú èdè wò ní wón ń sọ? Ọ̀gbẹ́ni Adébóyè Babalọlá sọ nínú ìwé kan tí àkọ́lé rẹ̀ ń jẹ "Introduction tó Nigeria Literature" Pé Olóògbé D. O. Fagunwa ni ó kọ́kọ́ kọ ìwé ìtàn àròsọ ní ọdún 1938 Ṣùgbọ́n ṣáájú Fagunwa ń kọ́?

Kí ni àwọn Yorùbá ń ka? Ṣé kò sí ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá ṣáájú Fagunwa ni? Àwọn ìbéèrè mẹta tó tẹle ará wọn yìí ni ó gún mi ní kẹ́sẹ́ inú láti ṣe ìwàdi lórí ìbẹ̀rẹ̀ àti ìdàgbàsókè eré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ Yorùbá, èyí tíì ṣe lára àwọn lítíréṣọ̀ Yorùbá.

Ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tí ó se okùnfà fún àtiwáyé eré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ Yorùbá ni sísọ èdè Yorùbá di kíkọ sílẹ. Láti ọjọ́ tí aláyé tí dáyé, èdè àfẹ̀nusọ ni èdè Yorùbá jẹ́. Ọjọ́ pẹ́ tí àwọn Yorùbá ti ní onírúurú ìbásepọ̀ pẹ̀lú àwọn orisirisi ẹ̀yà láàárín àgbáyé ní pàtàki àwọn Lárúbáwá, Hausa, Aganyin àti Òyìnbó. Ìbásepọ̀ Yorùbá pẹ̀lú wọn wáyé nípa òwò ṣíṣe tàbí ẹ̀sìn fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún tí wọn tí ń bá ara wọn ṣe pọ̀.

Ohun ẹnu àti àpéjúwe ní kókó ọ́nà tí wọ́n fi ń gbọ́ ara wọn yé. Ṣùgbọ́n ní kó-pẹ́ kò-jìnnà ni àyípadà dé tí èdè Yorùbá di kíkọ sílè. Onírúurú àwárí lọ tí wáyé lórí bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ silẹ, ọ̀pọ̀ ìwé ló sì ti jáde láti ṣe àfihàn èyí. Ṣùgbọ́n ní bayi, púpọ̀ ló ti jáde ní kíkún tí ó sì sọ bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ silẹ nítorí náà, a ó ṣe àlàyé ṣókí bí èdè yìí ṣe di kikọ silẹ, ìdí ni wí pé bí èdè Yorùbá kò bá di kíkọ silẹ kìí se àsìkò tí eré orí ìtàgé Yorùbá bẹ̀rẹ̀ nì bá tí bẹ̀rẹ̀, tàbí gbogbo ohun tí a ń sọ nípa èré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ. Yorùbá ni a bá máa sọ lónìí.

Àwárí ìmọ̀ lórí bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ sílè hàn pé ní nǹkan bí aadowa ọdún ó dín márùn-ún sẹ́yìn, 1815 ni òyìnbó kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ T. Ẹ. Bowdich ṣe àkójọ àwọn ọ̀rọ̀ Yorùba bíi mélòó kan. Àwọn ọ̀rọ̀ òǹkà bíi ení, èjì, ẹ̀ta, títí dé mẹwa ni Bowdich gbìyànjú láti kọ sílẹ̀. Ní ilẹ̀ Àgànyìn (Ghana) ni ó ti ṣe alaba pàdé àwọn ènìyàn

Yorùbá tí ó sì kọ àwọn ọ̀rọ̀ náà silẹ. Ìwọ̀nba ohun tí Bowdich ṣe yìí ni ó mú kí èdè Yorùbá di mímọ̀ fún àwọn òyìnbó tí ó ní ìmò nípa èdè.

Lára àwọn tí ó tún ṣe akitiyan láti rí pé èdè Yorùbá di kíkọ sílẹ̀, ni arábìnrin kan tí orúkọ rẹ ń jẹ́ Hannah Kilhan ni ọdún 1828.o ṣe àkójọpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ díè nínú èdè Yorùbá, ó sì tẹ wọn jáde sínú ìwé. Nípa báyìí, Hannah Kilhan ni ó jẹ ẹni Kìn-ín-ní nínú àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó tẹ àwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá jáde nínú ìwé. Àwọn òyìnbó mìíràn ní Clapperton, Raban, Herry Townsend àti Vollmer tí wón tún ṣe aápọn ńlá láti mú kikọ̀ èdè Yorùbá tẹ síwájú sí. Nígbà tí yóò sì fi di ọdún 1849 eré kéré tí di òdodo. Ọmọ oní ǹǹkan ti gba ọ̀rọ̀ kíkọ èdè Yorùbá kanrín.

Samuel Àjàyí Crowther Osoogun lẹ́bàá Ọya tí òun náà tí ni ìmọ̀ nípa èdè ti di ẹni pàtàkì nínú isẹ́ ìhìnrere tí ìjọ C. M. S.

Ní ọdún 1849 ni ó sì kọ́kọ́ ṣe ìwé gírámà èdè Yorùbá ni ọdún kẹwàá lẹ́yìn èyí ìyẹn 1959 kíkọ èdè Yorùbá sílẹ sì ti tẹ̀síwájú sii.

Lẹ́yìn - ọ̀-rẹyìn ni a rí àwọn olólùfẹ́ èdè Yorùbá kí ó tó di pé orísirísi àwọn tí ó ní ẹ̀bùn eré orí ìtàgé èdè Yorùbá. Onírúurú ìwé ìròyìn náà máa ń jáde. Aadowa ni ìyè tó jáde láárín ọdún 1859 si 1867. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìpàdé àti àpérò ló wáyé láti ṣe àyẹ̀wò àti àtúntò, àlàyé àti àsọyé nínú ìpàdé kan tó wáyé ní C. M. S. Ìta fààjì ní ìlú Èkó ní ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ́n oṣù kìn-ín-ní ọdún 1875, àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n nínú ìmò nípa èdè Yorùbá fẹnu kò lórí ìlànà fún kikọ́ èdè Yorùbá sílẹ̀. Ìlànà yìí ni púpọ̀ àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá tẹle títí di ọdún 1966 tí

ìjọba ìgbìmọ̀ tí ó ń ṣàkóso lórí àtúnṣe fún ìlànà kikọ́ Yorùbá sílẹ̀ dìde láti se àtúnṣe fún kikọ́ èdè Yorùbá silẹ.

Ànfààní ribiribi ni ìfẹnukò lórí ìlànà kíkọ èdè Yorùbá silẹ tí ọdún 1875 jẹ́ fún ìtẹ́síwájú èdè àti eré oníse tí ó jẹ ọ̀kan nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá. Lára àǹfààní bẹ́ẹ̀ ni pé ó pèsè ààyè sílẹ̀ fún gbogbo ẹni tí ó ní fẹẹ Yorùbá dìde láti tẹ̀síwájí lórí èdè abínibí láti fi èrò ọkàn wón hàn nípa kikọ̀ onírúurú ìwé ni èdè Yorùbá pẹ̀lú ìwúrí tí ó bùáyà.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá bèrè sí ní dídè tí wọn sì ń kọ onírúurú ìwé jáde ní èdè Yorùbá. Lára wọn ni Ọgbẹni I. M. Thomas tí ó gbé "ÌWÉ ÌRÒYÌN Eko jáde ní ọdún 1888. Ní ọdún 1897, Àlùfáà Ẹ. M. Lijach tẹ ìwé ifá Orunmila, ó sì jáde ní ọdún 1907. Ní ọdún 1911 àlùfáà Hinderer ṣe àtẹ̀jáde ìwé Pilgrim's Progress tí John Bunyan mọ̀ ni èdè Yorùbá, ó sì pe akọ́lé rẹ̀ ni "ÌLỌSÍWÁJÚ Ẹ́RO MÍMỌ́". Ní ọdún 1911 Akínyelé kọ́ ìwé ìtàn Ìbàdàn, Òsogbo, Ìwọ, àti Ìkìrun. Akitiyan àwọn ènìyàn wọ̀nyí mú orí yá ni.

Ṣùgbọ́n bí ǹǹkan tí ń lọ, ó dàbí ẹni pé àwọn ìwé tí ó ń jáde ọ̀rọ̀ ẹṣin Ìgbàgbọ́ àti ìtàn ìbílẹ̀ ni ó wọ́pọ̀ nínú wọn. Irú èrò báyìí lógún Ọgbẹni A. K. Ajisafe nínú tí ó fi bẹ̀rẹ̀ kikọ́ àwọn ìtàn aroso Yorùbá silẹ nínú ìwé kán sandi, gbagada ni Ajisafe là èrò ọkàn rẹ mọ́lẹ̀, nínú ìwé ìtàn òyìnbó tó, ó jẹ́ kí a mọ díẹ̀ nínú ìtàn ilẹ̀ wá, itan ìlú wá kún fún ẹ̀kọ́ àti ọgbọ́n.

Àwọn ìwé Ajisafe gbayì káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá, síwájú síi, àwọn ìwé Ajisafe fi hàn pé lai-sí-àní-àní, àwọn ìtàn Yorùbá gbádùn mọ́n sì jẹ orísun Ìkọ́ni àti ìtọ́ni "Ogunsina 2000".

## 1.2 BÍ ÌWÉ ERÉ ORÍ ÌTÀGÉ ṢÉ BẸ̀RẸ̀ ÀTI ÌDÀGBÀSÓKÈ RẸ̀

Gẹ́gẹ́ bí á ṣe mọ̀ pé okùn kìí gùn-gùn kí ó máa ní ibi tí ó ti ṣe wá, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni eré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ Yorùbá jẹ́. Bákan náà ni a gbọ́dọ̀ mọ pé kágbàdo tó dé ilé ayé nkankan ladìye tí ń jẹ, eré orí ìtàgé kìí se àjèjì ni ilẹ̀ Yorùbá kí ó tó di pé ẹ̀sìn Ìgbàgbọ́, ọ́làjú àti ẹ̀kọ́ òyìnbó dé, a ti ní onírúurú eré orí ìtàgé ni ilẹ̀ Yorùbá.

Encyclopedia Britanica Michropidia: ni ti ẹ̀ sọ pé "All forms of Drama Originated from the earliest worshiping of Gods, Idols which man later developed for moral teaching and societal enjoyment inform of acting on stage which is drama" (pg 185-205). Ìtumò èyí ni pé gbogbo eré orí ìtàgé bóyá èdè Yorùbá ni ó tàbí èdè mìíràn jẹyọ láti inú Ìbọ̀rìsà èyí tí àwọn ènìyàn tí tunṣe láti dán mọ́rán fún ìlò ènìyàn àti ìdárayá ni àwùjọ wá.

Tí a bá tún wo ohun tí Ogunsina 1980 náà wí ní tirẹ̀ sọ, ó ní orísirísi eré àwọn abọ̀rìṣà ni ó fara jọ eré orí ìtàgé. Àwọn ohun ìbílẹ̀ bí Sango, ọdún edi ni Ilé-Ifè, olooku ni òkùkù àti bẹẹ bẹẹ lọ ní o ni èròjà eré orí ìtàgé dáadáa. Gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wá nínú ètò ìbọ̀rìsà àti ẹ̀sìn, ọ̀pọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé àwọn òrìṣà máa wà àrà oríṣirìṣi èyí tí ó lè jẹ nípa ìgbésẹ̀ Ijo, ọ̀rọ̀ sísọ àti fífara janẹẹ. Nígbà tí orin sì jẹ́ èròjà àkókò nínú eré orí ìtàgé, àwọn ènìyàn pàápàá àwọn eléré apanilẹrin rí gbé

ìgbésẹ̀ àwàdà láti fi ṣe ìfarawé irú ìjọ tí wọ́n ń jó lásìkò ẹsin ìbọ̀rìsà yìí. Ibẹ̀ ní eré orí ìtàgé ti ń dìde díẹ̀ díẹ̀.

Nígbà tí eégún alárè bá ń pidán pẹ̀lú ijó, àwọn ọmọdé àti àwọn aláwàdà. Àwọn tí wọn ń panilẹrin kiri àdúgbò náà a máa ń ṣe àfarawé irú ìgbésẹ̀ yi títí tí àtúnṣe fi dé bá eré ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ èyí tí ó gòkè àgbà di eré orí ìtàgé loni yí.

## 1.3 BÍ ÌDÀGBÀSÓKÈ ṢE BÁ ERÉ ORÍ ÌTÀGÉ YORÙBÁ

Eré orí ìtàgé bẹ̀rẹ̀ nípasẹ̀ àwọn eégún aláre lẹ́yìn èyí ni ó wà rọ́ mọ àwàdà ṣùgbọ́n nígbà náà a kò ti mọ̀ọ̀n-ọ́n sì eré orí ìtàgé ni àsìkò naa: awada ni wọn mọ́n-ọn sì. Fún àpẹẹrẹ eré Bàbá Sàlá Aláwàdà èyí tó ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn-ọ-rẹyìn wá di eré orí ìtàgé ṣùgbọ́n nígbà tí ọ̀làjú bẹ̀rẹ̀ sí ní dé ni àwọn ènìyàn wá fún irú àwàdà ṣíṣe yìí ní àkọ́lé eréo orí ìtàgé. Àwọn ọ̀nà tí ìdàgbàsókè gbà wọ eré orí ìtàgé kìí se kékeré ṣùgbọ́n oríṣi ọ̀nà méjì ni àwọn ènìyàn ń gbà ṣe.

**(a) Ẹ̀sìn ìgbàgbọ́:** ìgbà tí a mú ẹ́sìn ìgbàgbọ́ wọ ilẹ̀ Yorùbá ni àwọn Yorùbá tó mọ̀ pé, gbogbo àwọn àṣà tí a ní wúlò tí ó sì ní iṣẹ́ tí wón ń ṣe, ṣùgbọ́n a kò mọ̀ ìwúlò wọn fún àpẹẹrẹ nígbà tí ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ dé àárín ilé Yorùbá ni eré orí ìtàgé tún gbilẹ̀ sì. Ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ yìí ló mú kí ẹ̀kọ́ àtòkèèrè wá rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ní pàtàkì, àwọn ọmọ lẹ́yìn Kristi sì tipa bẹ́ẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní kẹ́kọ̀ọ́ ní ilé ìwé. Nígbà náà ní a ti rí àṣà kí a máa tún fi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé mímọ́ ṣe eré orí ìtàgé, èyí tí àwọn ẹlẹ́sìn tún ń lò láti fi gba àwọn ènìyàn níyànjú àti láti fi kọ́ ẹ̀kọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Àwọn ọmọ ilé ẹ̀kọ́ àti àgbà kò gbẹ́yín torí pé àwọn gan-an

máa ń ṣeré orí ìtàgé fún ayẹyẹ ṣá ní ìkẹ́kọ̀ọ́ nílé ìwé wọn. Àpẹẹrẹ eré bẹ́ẹ̀ ni ìtàn ọba Sólómọ́nì níbi tí ìdájọ́ ti wà láàárín àwọn aṣẹ́wó méjèèjì tí wọ́n ń jà sí ọmọ. Bákan náà ni onírúurú àwọn ẹgbẹ́ aladani Òṣèré náà tún ṣe gudugudu méje àti yàyà mẹfà láti mú ìdàgbàsókè bá eré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ tàbí àpilẹ̀sẹ̀ Yorùbá lára àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ ni a ti rí akitiyan tí Hubert Ogunde, Dúró ládiípọ̀, Oyin Adéjobí, Adéyẹmí Afoláyan, Kọ́lá Ògúnmọ́lá, Moses ọláìyá kò sí àríyànjiyàn kankan nípa wí pé látinú àṣà ìṣèré tó tí wá ìyẹn egúngún alárìnjó ṣáájú kí àṣà, ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá, tó ó ní àwọn Òṣèré bíi Hulbert Ogunde papọ̀ tí wọ́n sì ń lò gẹ́gẹ́ bí ìlànà ti wọn. Àwọn ẹrú tí ó ti gba òmìnira tí wọ́n tún dé sí Ẹ̀kọ́ láti ilè sàró (Sierra Leone) àti kúbà ló kó àṣà ìṣere òkè òkun wọ èkó. Eré ní èdè Gẹ̀ẹ́sì sì ni ó wọ́pọ̀ nígbà náà. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó yá tí ọ̀rọ̀ kí a máa gbé àṣà ìbílè lárugẹ ń gbilẹ̀, wón bẹ̀rẹ̀ sí ṣe eré orí ìtàgé Yorùbá. "Sacred cantata" ati "Native Air Opera" ni irú eré orí ìtàgé le díè Yorùbá tí ó kókó gbilẹ̀ nígbà náà.

Àwọn akitiyan tí ó ṣe pàtàkì nígbà náà ni ti J. A Oyedele tí ó kọ eré "King elejigbo and princess Abẹ̀jẹ̀ of Kontangora", èyí tí àwọn ẹgbẹ́ ìfẹ́ ṣe ní ọdún 1903. Àṣeyọrí eré onítàn náà là lérò pé ó tún jẹ́ kí Oyedele kọ òmìnira tí ó pè ní "The Jealous Queen Oya of Oyo" tí àwọn ẹgbẹ́ ìfẹ́ kan náà ṣe ní 1905.

Àkíyèsí ni Wọ́n fi kọ àkọ́lẹ́ wọn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé eré onítàn ní èdè Yorùbá ni a pè wọn. Àṣà yìí sì fara hàn nínú eré orí ìtàgé tí Ogunde gan-an alára títí di àkókò bágbàmu ní ọdún 1965.

Ní ọdún 1910 ni ẹgbẹ́ "Glee Singer" tí ó ti máa ń ṣe eré ní èdè Gẹ̀ẹ́sì tẹ́lẹ̀ rí gbé ìkéde síta fún ìdílé ẹni tí ó bá le kọ eré onítàn tí ó dára lédè Yorùbá. Eré Olympus Moore "Asika bí Aparo" àti ti I. B Akinyele. "Àwọn ìwárẹ̀fà mẹ́fà" ni ó gbégbá orókẹ̀ nínú ìdílé náà. Lára àwọn eléré àkókò yìí tún ni A. B David, G. I Onimole, A. A Lẹ́yìn, H. A Olufoye, P. A Dawodu àti T. Ẹ. K Phillips ọdún 1944 ní àkọ́kọ́ gburo Ogunde nígbà tí ó ṣe eré onítàn "The Garden of Eden and The Throne of God". Gbogbo ìrírí rẹ̀ àtẹ̀yìnwá pẹ̀lú àwọn eléégún alárìnjó pẹ̀lú ni ó mú àfikún àwọn náà. Ní ọdún 1946 ni Ogunde tóó fi iṣẹ́ ọlọ́pàá tí ó ń ṣe sílè láti gbájú mọ́ eré orí ìtàgé gẹ́gẹ́ bíi iṣẹ́ àmúse.

A. A Láyẹni nìkan ni a gbó pé òun náà fi eré orí ìtàgé ṣe ojúlówó iṣẹ́ lára àwọn tí wón ń ṣe eré tẹ́lẹ̀. Àwòkọ̀se Ogunde ni a léro pé ó fún un ní ìwúrí. Ọdún 1946 yìí ni Ogunde ti bẹ̀rẹ̀ síí gbéré rẹ̀ káàkiri.

Oyin Adéjobí náà jẹ́ ènìyàn pàtàkì tí ipa rẹ̀ hàn lórí eré orí ìtàgé. Láìsí iyè méjì kankan a mọ̀ pé ìrírí Adéjobí pẹ̀lú ti àwọn òsèré rẹ̀ jẹ́ orísun fún gbogbo àwọn eré onítàn rẹ̀. A lè pín àwọn eré onítàn tirè sí ọ̀nà mẹ́rin gbòógì.

Àwọn ìsòrí mereerin náà;èyí tí ó gùn lé ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojumo láwùjọ, ní èyí tí ó fà yọ láti inú ìtàn ìsẹ̀dálẹ̀ Yorùbá, èyí tí ó gùn lé ìtàn inú Bíbélì àti èyí tí ó jẹ́ àyídà ìwé lítírésọ̀ mìíràn

Irú àwọn eré onítàn yìí ni ó pọ̀jù nínú àwọn eré onítàn Oyin Adéjobí, kò pọn dandan kí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó wà nínú eré onítàn bẹ́ẹ̀ ni "Teni ń Teni", orogún Adédigba, "Láníyonu" àti "Èkùrọ́ ọlọ́jà".

Àwọn òwò eré orí telifisan kòòtù Asípa, "Ilé ìwòsàn" àti " Lábúlé wa" náà wà nínú ìsòrí yìí Ẹ jẹ́ kí á ṣe àgbéyèwò "Èkùrọ́ olọ́jà láti fi ṣe àpẹẹrẹ eré onítàn tí ó wà ní ìsòrí yìí.

Lára àwọn kókó pàtàkì inú Èkùrọ́ ọ̀lọ́jà ni oyè dídùn láàárín àwọn ọmọ oyè àti àìsòótọ́ láàárín lókoláya. Láti ri pé oyè ìlú tí wọ́n ń dù já mọ́ òun lọ́wọ́, làágbé sa gbogbo agbára rẹ̀. Tóògùn ọ̀rẹ́ rẹ̀ náà sì ṣetàn láti ràn án lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n nítorí pé Tóògùn lẹ́sẹ̀, làágbé gba Díẹ̀kọ́là gbọ́ Tóògùn sì ní láti sá kúrò ní ìlú, nítorí ìtìjú, ó ń ló gbé oko. Nínú oko ni Tóògùn ti se alabapade Èkùrọ́ Olọ́bà, tí ọmọ oyè tí yóò bá jọba gbọdọ̀ wà kárí gẹ́gẹ́ bí àṣẹ ifá, níbi tí ó ti ń kó bẹ́.

Nígbà tí ìròyìn kàn dé ìlú Díẹ̀kọ́là sale lọ sí oko lọ́dọ̀ Tóògùn láti fi ọgbọ́n gba Èkùrọ́ olọ́bà náà mo ọn lọ́wọ́, ṣùgbọ́n kò bó síi fún un. Ọmọ oyè kejì, Tòkunbọ̀ ní Tóògùn fi Èkùrọ́ náà tọrọ fún nígbẹ̀yìn ọ̀rọ̀.

Ohun pàtàkì ni Oyin Adéjobí ń tọ́ka sí níbi tí ìyàwó alágbèrè ṣe lè jẹ́ ìdènà nínú ìtẹ̀síwájú ní ìgbésí ayé ọkọ rẹ̀, tí ó sì lè ba ààrín ọkọ àti àwọn ọrẹ rẹ̀ jẹ́. Kò sí ànì ànì pé irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ láwùjọ wa. Lọ́nà kan oyè ọba dídù mọ́ra ẹni lọ́wọ́ nípa títa ọgbọ́n àrékérekè orisirisi àti bíba ọmọlúwàbí ara ẹni jẹ́ láì bìkítà fún àwọn ará ìlú, ni Oyin Adéjobí gbé kalè. Irú dídu oyè mó ara ẹni lọ́wọ́ báyìí náà wà ní àwùjọ wa lóde òní yìí.

Ẹ̀kọ́ tí Oyin Adéjobí fẹ́ kí a kọ́ tí kò fi jẹ́ kí oyè jámọ́ làágbé òsebi ọmọ oyè lọ́wọ́ nínú eré onítàn náà ni pé irú ìwà tí òun àti àwọn alátìlẹ́yìn rẹ́ hù kò dára. Ibi tí ó yẹ kí ayé ó dorí kọ ni Oyin Adéjobí tọ́ka sí yẹn tí yóò fi dẹ gbogbo ará ìlú lọ́rùn. Ṣùgbọ́n a mọ̀ pé ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ ní àárín àwùjọ wa, àwọn òsebi gan-an ní wọ́n ń bọ́ sí ipò tí wọn sì túbọ̀ ń gbilẹ̀ sii nínú ìwà ibi wọn.

Bákan náà ni Kọ́lá Ògúnmọ́lá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn tí orísun àwọn eré onítàn rẹ̀ mú orisirisi ìrírí àwùjọ hàn nínú eré rẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Nígbà tí ó bá tilè mú ìtàn eré onítàn kan láti orísun mìíràn, a ṣe àkíyèsí pé ó máa ń ṣe àyídà irú ìtàn bẹ́ẹ̀ dáradára lọ́nà tí yóò fi wá ní ìbámu pẹ̀lú ìrírí ní àwùjọ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bíi àwọn àwùjọ ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù,Kọ́lá Ogunmola náà kọ àwọn eré onítàn adalórí ìtàn Bíbélì.

Àpẹẹrẹ ni "Reign of The Mighty", "Joseph and Brethren","Hannah's trial" àti "ọjọ́ ìbí Kristi".

Àpẹẹrẹ àwọn eré rẹ̀ tí ó mú láti inú ìtàn ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn ni "The palm Wine Drunkard" àti Àdìtú Olódùmarè" tí D. O Fagunwa kọ. Àwọn eré onítàn tí a lè sọ pé ó gùn lé ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ láwùjọ ni " Ìfẹ̀ Owó","Ọ̀fọ̀ Àgbà"," Bíkà kúure kò ní sún un rẹ".

Kò sí àní-àní pé Kọ́lá Ogunmola tún lo àwọn ìtàn Yorùbá pàápàá àwọn tí ó jẹ́ aalo onítàn. Àmúlò orísun yìí rinlẹ nínú "òrìṣà jẹ́ ń pè méjì obìnrin kò dénú","Hell on Earth", "Èṣù ọ̀dàrà", "Ọgbọ́n ju agbára" àti "Kádàrá ò papọ̀". Oyẹ́ kí á tọ́ka sí i pé foran àlọ́ onítàn náà rinlẹ̀ nínú "The Palm Wine Drunkard" àti "Àdìtú Olódùmarè "

ṣùgbọ́n látinú àwọn ìwé ìtàn àròsọ, tí Ogunmola tí fa àwọn eré náà yọ ní fọ́nrán náà ti wà tẹ́lẹ̀.

Dúró Ladiipo náà, gẹ́gẹ́ bí àwọn aṣáájú rẹ̀ náà kọ àwọn eré tí ó dá lórí ìtàn inú Bíbélì, ìyàtọ̀ tí ó kàn wà nípa tirẹ̀ àti ti àwọn yòókù ni pé àkọ́lé tí ó ń fún àwọn eré orí ìtàgé yìí kì í tètè jẹ́ kí ènìyàn mọ̀ pé eré orí ìtàgé tí a fà yọ látinú Bíbélì ni wọ́n.

Àpẹẹrẹ ni "Kọbi Idi" tí ó jáde láti inú ìtàn Dáfídì àti Golayati (Samuel 1:17) "jaleyemi" jẹ́ ìtàn tí a fà yọ láti inú ìtàn Sámúsìnì àti Delaila (onidajo 16) àti "Afolayan" tí ó jẹ jáde láti inú ìtàn Jósẹ́fù alálàá (Genesis 39).

Àpẹẹrẹ àwọn eré Dúró Ladiipo tí ó jẹ mọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ láwùjo ni "Ẹgbádégẹ̀sin", "Alágbára má mèrò", "Má gbára lé wọ́n", "Sùúrù Baba Ìwà", àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àpẹẹrẹ eré orí ìtàgé Dúró Ladiipo tí ó fà yọ látinú àwọn ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn ni "Ẹ̀dá" láti inú eré ayé àtijó kan ní èdè Gẹ̀ẹ́sì tí ó ń jẹ́ "Every Man", "Ọ́tún Akọgun" àti "ọmọnidẹ" jẹ́ àyídà eré "Shakespeare", Macbeth" àti "As you like it" Duro Ladiipo ṣe àmúlò ìtàn àti àṣà Yorùbá dáradára láti ṣe àyídà àwọn eré wọ̀nyí sí eré Yorùbá.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, èyí tí ó pọ́ jù tí ó sì gbajumo jù nínú àwọn eré Dúró Ladiipo ni àwọn tí ó mú jáde láti inú ìtàn ìwáṣẹ̀ ìyẹn ìtàn àwọn akọni ìgbaànì tàbí ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi. Díè lára àwọn eré onítàn bẹ́ẹ̀ ni "Ọba mọrọ", "Ọba Wọ̀jà," Ọba kòso", "Mọ́remi" pẹ̀lú "Ajagun ńlá".

Moses olaiya Adejumo (Baba Sala) bíi aṣáájú nínú àwọn eléré orí ìtàgé kò ìtàn Bíbélì a mò kankan lọ bí í tí àwọn eléré tí a ti sọ̀rọ̀ lé lórí. A lérò pé irú eré orí ìtàgé àrà ọ̀tọ̀ tí òun gbajúmò wà lára ohun tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ lọ́nà kan.

Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, àkókò ti lọ lórí irú eré orí ìtàgé bẹ́ẹ̀ nígbà tí olaiya bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe eré onítàn ní pẹrẹu ní ọdún 1965. Látinú ìrírí rẹ̀ nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ láwùjọ ni Moses Olaiya náà ti máa ń fa àhunpọ̀ ìtàn ọ̀pọ̀lọpọ̀ eré onítàn rẹ̀ jáde fún àpẹẹrẹ àwọn àgbàlagbà olówó láwùjo tí ó máa ń bá ọmọ ilé ẹ̀kọ́ tí ó jẹ́ obìnrin dá ọ̀rẹ́ ni Moses Olaiya fi sẹ̀fẹ̀ nínú eré rẹ̀ kan tí ó pè ní "Sugar Daddy" àwọn tí wọn jàjà lọ sí òkè òkun tí wọn kò jẹ́ ará ilé mi mó ni Moses Olaiya fi sẹ̀fẹ̀ nínú Tòkunbọ̀". Àwọn ọ́kánjúà tí ó máa ń wá ilé olókùn kiri níbi tí wọn ó ò ti jẹ oúnjẹ tí wọn óò sì mu ọtí ọ̀fẹ́ ni ó fi sẹ̀fẹ̀ nínú" ọmọlóò kú". Ìṣẹ̀lẹ̀ bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin ṣe ń sá lọ sí ìdí iṣẹ́ nígbà tí ogun abẹ́lé ní Nàìjíríà ni ó sì fi sẹ̀fẹ̀ nínú" ọmọ wásẹ́".

Lẹ́yìn èyí Moses Olaiya tún máa ń mú àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀ látinú ìtàn Yorùbá nígbà mìíràn. Èyí tí ó gbajúmò jù nínú irú eré orí ìtàgé bẹ́ẹ̀ ní ti "Abọ́ba kú". Àṣà bí olóyè ọ̀nà isokùn ṣe máa ń pa ara rẹ̀ nígbà tí Aláàfin Ọ̀yọ́ bá kú ní Ọ̀yọ́ ni Moses Olaiya fi sẹ́fẹ̀ nínú eré náà ṣẹlẹ̀ gan-an ní Ọ̀yọ́.

Ìwé ìròyìn àtijó, kó ipa pàtàkì nínú àtiwáyé ìwé orí ìtàgé Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí Ogunsina (1980)ṣe sọ. E. A Akintan bẹ̀rẹ̀ kíkọ eré orí ìtàgé kan sínú ìwé ìròyìn tó pe àkọ́lé rẹ̀ ní "Elétí ọfẹ". Òun gan-an kò tilẹ̀ mọ orúkọ tí ì bá fún àkọ́lé eré náà ó sáà kọ bíi mẹ́ta síbẹ̀, kí òǹkọ̀wé

lè mú èyí tí ó bá wù ú, lára àkọ́lé náà ni "pérìn díè", "pa mí ń kú obìnrin", Ẹní máa kú pàdé ẹní máa pá" gbogbo àkọ́lé wọ̀nyí jẹ́ ọ̀nà láti derin pa àwọn òǹkọ̀wé. Ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ́ sì ni eré náà ń gbà jáde ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀.

A rii pé kété tí ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ wọ àwùjọ àwa Yorùbá tí ìwé kíkà ti wá ń gbilẹ̀ ní ìwé ìròyìn pàápàá ti bẹ̀rẹ̀ sí di kíkà. Ìwé ìròyìn "Elétí ọ̀fẹ́" tí wọ́n pèní "pa mí n kú obìnrin". Láti àsìkò yìí ni eré orí ìtàgé ti wá bẹ̀rẹ̀ sí ní gòkè si.

Lẹ́yìn ọdún 1958 sí ọdún 1964 àkọsílẹ̀ kò fi bẹ́ẹ̀ sí lórí eré orí ìtàgé Yorùbá. Ṣùgbọ́n èyí kò sọ pé eré orí ìtàgé kò ní wáyé láàárín àwọn àkókò yìí. Ní ọdún 1965 Afolabi Olabintan gbé eré orí ìtàgé ti rẹ̀ jáde, tí ó pe àkọ́lé rẹ̀ ní "Òrékelẹ́wà" gbogbo àwọn eré wọ̀nyí ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bíi ìdàgbàsókè tí ó dé bá eré orí ìtàgé Yorùbá.

Lẹ́yìn ọdún 1969 ìwé eré orí ìtàgé Yorùbá ti wà ń gbilẹ̀ si, ṣùgbọ́n sá, àwọn onímò sọ pe ní ọdún 1970 gan-an ni a le tọ́ka sí pé eré orí ìtàgé Yorùbá tí ó jé àpilẹ̀kọ wà lalẹhi tí ọwọ́ ìjà rè sí gba ilẹ̀ gbogbo. Ní ọdún yìí kan náà ni a lè tọ́ka sí iṣẹ́ Akinwunmi Isọla tí a mọ̀ sí eré onítàn Ẹfúnsetán Aníwúrà.

## 1.4 Àpẹẹrẹ Ìwé Àti Òǹkọ̀wé Eré Oníse Ní Ṣókí

**1. J. F Odunjo:** jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn tí ó ń kọ ìwé ìtàn àròsọ àti eré orí ìtàgé àpilẹ̀kọ ní èdè Yorùbá. Lára ìwé eré orí ìtàgé tó kọ ni "Agbajọwọmerin Baálè Jontolo" ní ọdún 1958.

**2. Lawuyi Ogunniran:** jẹ́ ẹni tí ó máa ń ronú jinlẹ̀ lórí àwọn ohun tí ó wà ní àyíká rẹ tí yóò wá sọ́ di mímọ̀ fún àwọn olólùfẹ́ èdè Yorùbá. Òun ni ó kọ ìwé eré orí ìtàgé "Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí" ní ọdún 1977.

**3. Akinwunmi Isọla:** ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá tí ó máà ń kọ onírúurú ìwé ìtàn àròsọ àti eré orí ìtàgé ni. Òun ni ó kọ́ ìwé eré orí ìtàgé "Ẹfúnsetán Aníwúrà" ní ọdún 1970 àti Fíìmù "Ó le kú" ní ọdún 1974.

**4. Oladejo Okediji:** jẹ́ ẹni tí ó ní ẹ̀bùn atinuda èyí tí ó jẹ́ kí ó máa kọ àwọn ìwé eré orí ìtàgé ní èdè Yorùbá. Òǹkọ̀wé yìí ni o kọ́ ìwé eré orí ìtàgé "Rẹ́rẹ́ Rún" ní ọdún 1973.

**5. Adebayo Faleti:** ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn tí ó máa ń ronú jinlẹ̀ lórí àwọn ohun tí ó wà ní àyíká rẹ̀ èyí ló mú kí ó máa kọ onírúurú ìwé ìtàn àròsọ àti eré orí ìtàgé lorisirisi, òun ni ẹni tí ó kọ ìwé eré orí ìtàgé "Basorun Gaa" ní ọdún 1972,"Ìdààmú paadi Minkailu" ní ọdún 1958 àti "Fere bí Ẹkùn" ní ọdún 1957.

**6. Ọ̀jọ̀gbọ́n Tunde Kelani:** Bákan náà ni ọ̀jọ̀gbọ́n Tunde Kelani náà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn tí ó máa ń ronú jinlẹ̀ lórí àwọn ohun tí ó wá ní

àyíká rẹ. Èyí ló ṣe àgbékalè ìtàn fíìmù àgbéléwò "Agogo Èèwọ̀" àti àwọn onírúuurú isẹ́ mìíràn lórí eré orí ìtàgé títí di ọdún tí a wà yìí.

## ORÍ KEJÌ

## 2.0 NÍPA FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

Fíìmù agogo èèwọ̀ jẹ́ eré orí ìtàgé tí ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola ṣe àgbékalè ni ìrántí àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n tí wọ́n ti ṣe gudu gudu méje òhun yàyà mẹ́fà nínú ètò òsèlú ni ilẹ̀ adúláwò. Lára àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ níí, Olóyè Bọ́lá ìgè ni ọdún 1930 sì 2001; Wálé Ogunyemi ni ọdún 1939 - 2001; Bassey. W. Andah 1942 - 1997 àti Sade Ladipo Àjàyí 1949 sì ọdún 2001.

Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola wo bí wọ́n ṣe gbìyànjú lórí ètò ìṣèlú àti ipa ribiribi tí wọ́n ṣe, èyí ló mú sọ di ìtàn tí wọ́n sì ṣe àgbékalè rẹ ni ọdún 2002. "AGOGO Ẹ̀ẹ̀wọ̀" ń ṣe àfihàn bí àwọn ènìyàn kan ṣe ń fẹ́ ìlọsíwájú ìlú tí àwọn ẹ̀dá mìíràn sì jẹ ọ̀jẹ̀lú. Irúfé àwọn ẹ̀dá wọ̀nyí ni a lè rí i nínú fíìmù àgbéléwò náà.

## 2.1 ÀGBÉYÈWÒ ÈTÒ ÒṢÈLÚ INÚ FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

Ẹni tí kì í bá ṣe Yorùbá àti àlejò òkèèrè, a máa sọ pé Ọba Yorùbá ni ó láṣẹ àti pé bí ó bá ti fẹ́ ni ó lè ṣe Ìjọba rẹ. Òwe àwọn àgbà tí wọ́n sì ń pá pé ''Ibi tí ó wùu ẹ̀fúùfù lẹ̀lẹ̀ níí dárí ìgbẹ́ sì, ibi tí ó wù olówó ẹnì ni í rán ni lọ'' dàbí ẹni pé àwa Yorùbá náà kín ọ̀rọ̀ àti èrò àwọn àjòjì yìí lẹ́hìn, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bí a ti ń wò ó l'ókeere yìí, a kì í sì gbé òkèèrè mọ dídùn ọbẹ̀ l'ase bí tí ìjọba Lápitẹ́ àti Làgàta tí wọ́n jẹ́ Ọba Ìlú Jogbo.

Ìlú Jogbo bí orò Jogbo bí oró kún fún wàrà àti oyin, ṣùgbọ́n àwọn adarí wọn tí wón dúró gẹ́gẹ́ bí Ọba ń ṣe ìlú náà ni ise kú-ṣe bí wọ́n se fẹ́. Gẹ́gẹ́ bí ọba àkọ́kọ́ tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ "LÁPITẸ̀" pẹ̀lú àwọn ìjòyè rẹ bíi "Sérìkí àti Balógun" ṣe ń darí gbogbo ọrọ̀-ajé ìlú sì àpò ara wọn nìkan. Àjèjì ọwọ́ kan kò gbé ìgbà d'órí ni ọba ń lò. Àgbájọ ọwọ́ tí a fi sọ aya ni agbára tí ọba 'Lápitẹ́ ń lò lórí àwọn ará ìlú.

Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn àwọn ọ̀dọ́ Ìlú gbìmọ̀pọ̀ láti kọjú ìjà ńlá sí ọba, nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ni àwọn ọ̀dọ́ tí jì "Adé ìdẹ'' tí ìlú "Òní Jogbo'' ṣùgbọ́n Adé Idẹ kò gbọdọ̀lọ ọjọ́ méje níta. Bayi ni ọba k'ésí olórí ológun láti rán òun lọ́wọ́, kí ó sì rí pé òun gba Adé-Idẹ náà padà lọ́wọ́ àwọn ọdọ. Ọga-gun Làgàta gbéra pẹ̀lú àwọn ọmọ-ogún rẹ, wọn k'oju àwọn ọdọ wọ̀nyí.

Nígbà agbára àwọn ohun ìjà tí wọ́n ní, wọ́n gba Adé-Idẹ padà lọ́wọ́ àwọn ọ̀dọ́. Àsẹ̀yín-wa-àsẹ̀yìn-bọ̀ inú Lápitẹ́ dùn fún ìgbésẹ̀ akin àwọn ológun. Ní ọjọ́ ayẹyẹ, ní ọba Lápitẹ́ ti béèrè lọ́wọ́ olórí ológun wí pé kí ó sọ ohun tí ó fẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹbun fún ìṣe akin tí ó ṣe yìí. Ọ̀gá-gun Làgàta kò b'èsù b'ẹ̀gbà rárá Adé-Idẹ ni ó t'ọ́kasí wí pé kí ọba gbé Adé náà lé òun lórí.

Báyìí ni ìjọba tún bọ́ s'ọ́wọ́ Làgàta òun náà bẹ̀rẹ̀ sí se ètò ìlú Jogbo bí ó ṣe fẹ́. Kò-pẹ́-kò-jìnnà olórí ológun náà fẹ́ ṣe ayẹyẹ ìgba'-dé. Òun náà lọ gbogbo agbára tí ó ní lórí "Àyàn-galú" láti wá lu ìlù saworodẹ fún ọba tuntun. Kété tí àwọn ọdọ ìlú gbọ, wọn lọ bá Àyàn-galú láti gbé ìlù saworodẹ gan-gan dání pẹ̀lú àwọn onílù yòókù tí wọn kò ìlú dání.

Nígbà tí ayẹyẹ bẹ̀rẹ̀ tí wọn gbé Adé-Idẹ lè ọba lórí tí àwọn onílù náà bẹ̀rẹ̀ si ni lọ ìlú ni "Ayanniyi ọmọ Àyàn-galú náà gbé ìlú 'saworodẹ" tí ó jẹ ti ilu Jogbo jáde ti o bẹ̀rẹ̀ si ni lu, kété tí ọba tuntun gbọ ohun ìlú yìí ní ọ̀run tí bẹ̀rẹ̀ si ni wọ̀ ọ́, bayi ni olórí ológun, Ọ̀gà-gun Làgàta náà kú tí àwọn ìjòyè sì tún ronú lórí ọba mìíràn.

Èyí ló mú wọn tún tẹsiwaju láti lọ bá. "Bọsípò", Nipà gbogbo ìlà kàkà wọn lórí Bọsípò, Bọsípò gba láti tún di ọba Oní-Jogbo, ní rètí wí pé àwọn yóò tún máa ṣe ìlú ni ìse-kú ṣe. Balógun àti Sérìkí ṣe ọpọlọpọ wàhálà lórí Bọsípò ṣùgbọ́n lẹ́yìn ayẹyẹ ìgba'de ni wọn tó mọ wí pé ìjọba àtijọ́ tí yìí padà. Oní-Jogbo tuntun yìí kò fi gbogbo ara mọ ìmọ̀ràn wọn.

## 2.2 ÀWỌN KÓKÓ INÚ FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

Àwọn kókó tí ó jẹyọ nínú fíìmù Agogo Èèwọ̀ ni wọ̀nyí:

i. Òye dídù

ii. Ìs'owó ìlú kúmọ-kùmọ

iii. Ìwà ìpànìyàn

iv. Ìwà Àìlóòótọ́

v. Ẹ̀sìn ìbílẹ̀ ṣíṣe

**A. OYÈ DÍDÙ:-** Èyí jẹ́ kókó kan pàtàkì tí òǹkọ̀tàn gùnlé lórí nínú eré orí ìtàgé Agogo Èèwọ̀.Ọ̀ńkọ̀tàn jẹ́ ká rí àwọn ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan tí irú

ìwà yìí wọ l'ọ́rùn púpọ̀ nínú ìtàn náà. Àwọn wọ̀nyí nii Lápitẹ́, Làgàta, Balógun, Sérìkí, Ayangalu àti Bọsípò; ni èyí pọ̀ sí l'ọrun.

Ìṣẹ̀lẹ̀ òye dídù mú kí ọ̀pọ̀ àwọn èniyàn ní ìlú Jogbo sọ ẹ̀mí wọn'nu pàápàá julọ àwọn ọdọ ìlú náà. Nínú èyí tí àwọn ológun lọ ọ̀pọ̀ agbára wọn lórí àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí.

**B. ÌSOWÓ ÌLÚ KÚMỌKÙMỌ:-** Èyí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn kókó mìíràn tí ó ṣe pàtàkì nínú eré oníse Agogo Èèwọ̀. Àwọn tí a lè tọkasi nípa irú ìwà tàbí ìṣe sì yìí ni: Lapitẹ, Sérìkí, Balógun àti Ìyálóde. Àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí ni òǹkọ̀tàn gbé ìwà yìí wọ l'ọrun nínú ìtàn náà. Àwọn wọ̀nyí pẹ̀lú ọba ń ná owó ìlú bí wọn ṣe fẹ́, èyí kò jẹ́ kí wọ́n rántí àwọn ọ̀dọ̀ ìlú àti ìlọsíwájúsi ìlú Jogbo. Asẹyin-wa-asẹyin-bọ agbára bọ lọ́wọ́ wọn, ipò pàápàá náà tún-bọ lọ́wọ́ wọn, sì ọwọ Bọ̀sípò ọba tuntun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ ní ìlú Jogbo-bi-oró-Jogbo-bi-orọ̀.

**D. ÌWÀ ÌPÀNÌYÀN:-** Jẹ ọ̀kan nínú àwọn kókó tí ó suyọ̀ nínú eré oníse Agogo Èèwọ̀ láti ìgbà tí òǹkọ̀tan tí ń bá bọ nípa "Saworodẹ" títí tí ó fi d'orí AGOGO Èèwọ̀. A lè tan-mọn-ọn iṣẹlẹ sì àkókò tí Lapitẹ rán Ọ̀gá-gun Làgàta láti lọ gba Adé-Idẹ lọ àwọn ọdọ, ọpọ ẹ́ẹ̀mi ni àwọn ológun fi s'ofo sínú igbó tí wọn ba àwọn ọdọ ìlú wonyi.

Bákan náà ni Sérìkí àti Balógun ń l'epa Arẹ́sẹ̀-jabata àti Arápá-re-gán-gan láti páwon nítorí ipò ọba; ṣùgbọ́n ọba òkè lọ gba sílẹ̀ nínú ìdàámú yìí. A tún lè tọ́ka ìwà yìí nígbà tí Ọga-gun Làgàta gba Adé-Idẹ dé sí ààrín ìlú ni ọjọ́ ayẹyẹ ni òun náà ṣe ikú pá ọba Lápitẹ́ nítorí pé òun náà dé láti di ọba ìlú "Jogbo".

**E. ÌWÀ ÀÌLÓÒÓTÓ:** Òun náà tún jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú eré orí ìtàgé yìí, nítorí pé òǹkọ̀tàn jẹ́ kí a rí bí àwọn ènìyàn ṣe ń dá ara wọn tí wọ́n sì ń fẹ́ láti lọ ìfẹ́ inú wọn láti dé ipò tí wọn fẹ. A lè tọ́ka èyí sì àwọn ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan tí ó ní irú ìṣe yìí. Àwọn wọ̀nyí nii Olóyè Séríkí, Olóye Balógun, Ìyálóde, Lápitẹ́ , àti Làgàta. Àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí jẹ́ ẹnì tí onkọtan náà gbé irú àwọn ìṣe sì wọ̀nyí wọ l'ọrun nínú ìtàn náà.

**Ẹ. Ẹ̀SÌN ÌBÍLẸ̀ ṢÍṢE:** Náà jẹ kókó kókó mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì nínú eré orí ìtàgé Agogo Eewọ. Èyí ni a lè tọ́kasí nígbà tí ọba bá fẹ́ wá l'órí ìtẹ́ àwọn bàbá-ńlá wọn, nínú èyí tí ó ṣe pàtàkì fún irú ẹni bẹẹ láti sìn gbẹ́rẹ́ tí yóò jẹ́ onírúurú òògùn bákan náà. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn gbogbo àwọn ètùtù wọ̀nyí ni wọn yóò tó lu ìlú 'Saworodẹ' sì ọba náà l'eti. Látàrí ìsesí yìí àwọn ọba mìíràn kò dúró parí ètùtù bákan náà àwọn mìíràn kò dúró sìn gbẹ́rẹ́ yìí, èyí tí ó ṣokùnfà ikú òjìji fún ọba 'Lápitẹ́ àti ọba Làgàta nínú eré oníse yìí ; ọba Bọ̀sípò náà wá lára àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà, o padà dojú kọ ní ìkẹyìn nínú 'Agogo Eewọ'. Èyí tí ó fún "Arẹ́ṣẹ̀-Jabata" ni àǹfààní láti gorí ipò àwọn babanla rẹ, nítorí òun sìn gbẹ́rẹ́ yìí, ó sì tún jẹ́ gbogbo àwọn ohun ètùtù tí ó yẹ kó ṣe gẹ́gẹ́ bí ọba Oní'Jogbo.

## 2.3 ÀHUNPỌ̀ ÌTÀN INÚ FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

**ÌSÍDE ÌTÀN:** Ìtàn yìí bẹ̀rẹ̀ láti orí ọba tuntun tí wọn ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ fi jọba ní ìlú Jogbo-bi-oró-jogbo-bi-orò. Ọba Bọ̀sípò ni àwọn olóyè ìlú lọ bá l'ẹ́nu ìṣẹ́ rẹ, níbi tí ọtí ń gbìn àwọn ohun eléso. Àwọn olóyè wọnyi ni Séríkí, Balógun àti olóyè ọ̀tún, wí pé ó ti di dandan fún Bọ̀sípò láti wá j'ọba tí ìlú Jogbo báyìí. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn Bọ̀sípò pinu wí pé òun á

máa ronú sì ọ̀rọ̀ náà ṣùgbọ́n wọn kò fún ní àǹfààní láti ṣe èyí; àwọn olóyè wọ̀nyí ṣí fìlà l'órí láti kí ọba tuntun náà.

**ÒTÉŃTÉ ÌṢẸ̀LẸ̀:** Ìṣẹ̀lẹ̀ àkọ́kọ́ gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó wáyé nínú 'Agogo Eewọ' ni, ìgbà tí Bọ̀sípò de ilé rẹ láti ṣàlàyé ohun tí ó ṣẹlẹ̀ fún ìyàwó rẹ 'Lápé' wí pé àwọn olóyè ìlú wá bá òun láti jẹ oní-jogbo tuntun. Inú 'Lápé' ìyàwó rẹ dùn púpọ̀ láti gbọ́ èyí, nítorí pé òun yóò di olorì ọba. Asẹyin-wa-asẹyin-bọ, 'Bọ̀sípò' sọ fún ìyàwó rẹ pé òun kò ní owó láti na, pàápàá julọ wàhálà tí wọn ń ṣe, òun kò nifẹ si ipò náà.

Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn 'Bọ̀sípò' gbà láti di ọba ìlú Jogbo tí wọn sì ṣe àwọn ètùtù tí ó yẹ fún-un gẹ́gẹ́ bí Oní-jogbo kẹta. Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tí ó wáyé nínú ìtàn eré orí ìtàgé 'Agogo Eewọ' níbi ayẹyẹ ìfini-joyè, lẹ́yìn tí ọba tuntun tí bá àwọn ará ìlú s'ọrọ náà ni àwọn òní ìwé-ìròyìn ń bá bèrè ìbéèrè lọ́wọ́ ọba ní pá àwọn olóyè tí wọn jẹ ọ̀jẹ̀lú, ṣùgbọ́n tí ọba Bọ̀sípò tún gbà mọ́ra gẹ́gẹ́ bí olóyè rẹ. Àwọn wọ̀nyí ni 'Sérîkí, àti Balógun.

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn ni lẹ́yìn ayẹyẹ ìfinijoyè ni ìyàwó ọba tún gbà ní ìmọ̀ràn láti gbọ òun ti olóyè Sérîkí àti Balógun ń bá wa s'ọdọ oba; èyí ni pé àwọn olóyè wọ̀nyí ń fẹ́ kí ọba tun padà sí ìdí ìwà ibajẹ. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn ọba Bọ̀sípò náà kọ jalẹ fún àwọn ará ibí .

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún ní ìgbà tí Arápá-re-gángan àti Arẹ́sẹ̀-Jabata ń rántí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ sí Arẹ́sẹ̀-Jabata nípa ikú bàbà àti ìyá rẹ tí ó wáyé làtàrí ipò ọba tí wọn ń du láàárín ìlú Jogbo.

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún wáyé nígbà tí Bàbá Bọsun ń ṣe itọju ọkọ̀ rẹ̀, èyí mú kí ọkàn lára àwọn onibara rẹ, bẹ̀rẹ̀ si ni k'ọrin bù wí pé ọkọ kékeré ni ó ra tí kò jẹ ki ìlú sinmi, ìṣẹ̀lẹ̀ yìí mú ìjà wá láàárín òun àti ọmọbìnrin náà. Nínú itẹsiwaju ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ní ìyá àgbà tí ń kọ ọmọdé bìnrin kékeré kan nípa bí wọn ń we gèlè. Gẹ́gẹ́ bí ìyá àgbà náà tí wí; òní àwọn ọmọdé máa ń we "gèlè sì iwájú" àwọn ọlọmọge tàbí adélébọ̀ọ̀ má ń we tí wọn 'sì ẹgbẹ́' àwọn Agbà máa ń parí tí wọn sì ẹyin ni torí pé àwọn tí dàgbà.

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún wáyé nígbà tí Ẹyẹ́bà ń kọ̀wé sì 'Falọla' wí pé kí ó mai tí wálé nítorí pé ìlú ò f'araro rárá. Bákan náà ohun gbogbo kò ti dúró gẹ́gẹ́ bí ó ṣe yẹ.

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún wáyé nígbà tí àwọn olóyè 'Séríkí àti Balógun' wá bá ọba wí pé kí wọn bẹ̀rẹ̀ si ni na owó ìlú bí wọ́n ṣe fẹ́. Ṣùgbọ́n oni-jogbo k'ọjalẹ fún wọn wí pé òun kò ní fọwọ́ sì ìwà pála-pàla bẹ́ẹ̀ mọn-ọn. Asẹyin-wa-asẹyin-bọ ọba Bọ̀sípò náà bẹ̀rẹ̀ ìwà ibajẹ tí rẹ náà, wá lè ju ti àwọn ìṣáájú lọ.

**ÌKÁÀDÍ:** Lẹ́yìn tí ohun gbogbo tí ń lọ gẹ́gẹ́ bí oni-jogbo tuntun tí ṣe fẹ; l'ẹnu ìwà ìbàjẹ́ ni ọba Bọ̀sípò náà kú lè lórí.

Gẹ́gẹ́ bí ìpinnu àti lọ k'awe 'Arẹ́sẹ̀-Jabata' ó parí ẹ̀kọ́ rẹ lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn ojú na padà d'ade àwọn bàbà-ńlá rẹ, tí ó jẹ wí pé bàbà àti ìyá rẹ kú lè lórí. 'Arẹsẹ-Jabata' niti rẹ tẹ́lẹ̀ tí sìn gbẹrẹ; èyí ló ṣokùnfà kí wọn lu ìlù Saworodẹ ni etí rẹ tí kò sì ohun-kánkán tí ó ṣẹlẹ̀ sí.

Ìlú Jogbo-bi-oróJogbo-bi-orò bẹ̀rẹ̀ si ni dàgbà lọ́ tun-ọ̀tun, gbogbo àwọn ọ̀dọ́ ìlú bẹ̀rẹ̀ si ni gbádùn pelu ọba tuntun àti ìyàwó rẹ 'Arapa-re-gangan' nínú afin bàbà-ńlá wọn.

Bayi ni ìtàn náà lọ títí tí ó fi parí sì èbúté Ògo àti ayọ̀.

## 2.4 ÀPÈJÚWE ÀWỌN Ẹ̀DÁ ÌTÀN INÚ FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

Onírúurú ni àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó wà nínú fíìmù 'Agogo Eewọ' Àwọn tí ó ṣe pàtàkì nínú wọn, ní wọ̀nyí:-

1. Bàbá àgbà (Adebayo Faleti), Amawomárò (Fatomi lọla), Bọ̀sípò, Ẹyẹ́bà, Lápé, Séríkí, Badà, Balógun, Arẹsẹ-Jàbata, Ìyálájé, Ìyàlóde, Àwọn Ọ̀dọ́ Ìlú Jogbo, Bàsírá , Ọ̀tún.

**A. BÀBÁ ÀGBÀ (ADEBAYO FALETI):** Jẹ ẹ̀dá ìtàn kan pàtàkì jùlọ ninu fíìmù àgbéléwò Agogo Eewọ. Òun gan-an ni ẹni tí ó ń tọka sì ìwà ibajẹ tí àwọn olórí ìlú ń hù. Bákan náà ni ó jẹ ẹni tí ó máa ń fi orin bá àwọn ọbayejẹ wọ̀nyí wí. Bàbá Àgbà ní ẹni tí ó kọ lẹ́tà sì 'Falọla' wí pé kí ó máa wà lè nítorí pé ìlú kò fi ara rọ fún t'ẹru t'ọmọ,

**B. BỌ̀SÍPÒ :** Jẹ ẹ̀dá ìtàn tí ó ní ìfẹ́ lati J'ọba Ìlú Jogbo láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹpẹ ìtàn yìí, ṣùgbọ́n ní pá ìdààmú àti wàhálà, àwọn tí ó ní ìfẹ́ sì ipò náà, mú kí ó jawọ nínú ìdíje náà pẹ̀lú àwọn akẹgbẹ rẹ tí wọn jẹ 'Lápitẹ́' àti 'Làgàta' nígbà náà. Asẹyin-wa-asẹyin-bọ lẹ́yìn ikú àwọn ọba méjèèjì yìí Bọ̀sípò padà bọ-sì-pọ náà gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ. Òun ni ọba ìlú Jogbo tìtí tí ikú fi padà pá. Lẹ́yìn ìlú Bọ̀sípò ni ọmọba 'Arẹsẹ-Jàbata' padà sí orí ipò àwọn bàbà-ńlá rẹ gẹ́gẹ́ bí Òni'jogbo tí Ìlú Jogbo.

**D. ẸYẸ́BÀ:** Òun ni ẹni tí ó ń ba bàbà àgbà kọ lẹ́tà sí 'Falọla' wí pé kí ó máa ṣe wálé rárá, látàrí àwọn tí ó ń ṣe kú pá ara wọn lórí ipò ọba ò s'ọba.

**E. LÁPÉ:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn tí ó ní fẹ́ sì ipò ọlá nínú 'fìimù Agogo Eewọ' òun ni ó ń fẹ́ kí ọkọ rẹ gbà Ipò ọba ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn yìí, ṣùgbọ́n tí gbogbo erongba rẹ náà kò bọ sì rárá nígbà náà. Lẹ́yì-ọ-rẹyin tí ipò ọba náà bọ s'ọwọ ọkọ rẹ padà òun ni olórí ọba tuntun tí orúkọ rẹ ń jẹ 'Bọ̀sípò' nínú eré ori ìtàgé náà.

**Ẹ. SÉRÍKÍ:** Ọkàn pàtàkì nínú àwọn ọ̀dàlẹ̀ ẹ̀dá inú eré 'Agogo Eewọ' ni ẹ̀dá ìtàn yìí jẹ. Òǹkọ̀tàn pilẹ gbé ìwà arekereke wọ ẹ̀dá ìtàn yìí l'ọ́rùn láti ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn náà títí dé ìparí ìtàn. 'Séríkí' fẹ́ràn láti máa ṣe owó ìlú kúmọ-kùmọ pẹ̀lú àwọn akẹgbẹ́ rẹ àti ọba. Látàrí ìwà yìí 'Séríkí' padà di èrò ọ̀run nígbà tí ó kọ̀ láti jẹ́wọ́.

**F. BADÀ:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn kan tí òun náà fẹ́ràn ìwà ìbàjẹ́ nínú eré orí ìtàgé yìí. Òun ni ó pẹ̀lú àwọn olóyè tuntun tí ọba Bọ̀sípò tún yàn padà s'órí oyè. Ó tún wá lára àwọn tí ó ṣokùnfà ikú Ayan-galu àkọ́kọ́ tí ó jẹ́ bàbà 'Ayanniyi'. Ó tún bọ́ lọ́wọ́ ikú lẹ́yìn tí ó jẹ́wọ́.

**G. BALÓGUN:** Ẹ̀dá ìtàn kan pàtàkì láti ìbẹ̀rẹ̀ tí de ìparí ìtàn, ní Onkọtan tí gbé ìwà ìbàjẹ́ wọ lọ́run gẹ́gẹ́ bí aṣọ. Bí ó ṣe ń gba iwájú ló ń gba' ẹ̀yìn ṣe ìwà búburú yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ de òpin ìtàn náà. Lẹ́yì-ọ-rẹyin Balógun padà di èrò ọ̀ọrun nígbà tí ó kọ̀ láti jẹ́ wọ́.

**GB. ARẸ́ṢẸ̀-JÁBÀTÁ:** Jẹ ọkan pàtàkì nínú fiìmù 'Agogo Èèwọ̀' láti ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn yìí ní o ti ń l'ójú ìṣòro kan sì ó miíràn láti ìgbà tí eré náà tí bẹ̀rẹ̀ títí dé orí ìpele tí ó dé yìí ni ó ti ń k'oju ìṣòro kan sì ìkejì.

Àkọ́kọ́ nínú ìṣòro tí ó k'ojú ni, nígbà tí ó wà ní kékeré ni wọ́n ti pá Ìyá àti bàbà rẹ, lórí ọ̀rọ̀ òye ọba ìlú Jogbo.

Bákan náà ni ó jẹ ẹ̀dá ìtàn tí ipò ọba ìlú náà tọ́sí, ṣùgbọ́n àwọn àgbààgbà olóyè tí wọ́n jẹ́ ọ̀jẹ̀lú kò fún ní àǹfààní láti dé ipò náà. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn tí ọba ìlú 'Jogbo' tí orúkọ rẹ ń jẹ Bọ̀sípò kú ní tó ní àǹfààní láti bọ sì orí ìtẹ́ àwọn bàbà-ńlá rẹ̀.

**H. ÌYÁLÁJÉ:** Jẹ ọkan nínú ẹ̀dá ìtàn tí ó kúndùn ìjẹkújẹ pẹ̀lu àwọn olóyè bí 'Séríkí, Balógun àti Ọtun lááárín ìlú. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn, nígbà tí wọ́n lọ gba owó ẹyín tí èyí sì hàn sí ọba, ọba pàṣẹ wí pé kí wọn búra lórí ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Ní ọjọ́ ìbúra ní 'Iyalaje' jẹ'wọ ọrọ náà; bayi ni ikú ṣe yẹ lórí' Iyalaje'.

**I. ÌYÁLÓDE:** Òun náà pẹ̀lú àwọn ẹ̀dá ìtàn inú fiìmù 'Agogo Eewọ' tí ó pẹ̀lú àwọn tí ó jẹ ìjẹkújẹ pẹ̀lú àwọn olóyè yòókù. Òun náà padà jé'wọ́, wí pé òun náà gbà owó ẹyin l'ọ́wọ́ àwọn ilé ìṣe ńlá-ńlá láàrin ìlú lẹ́yìn ìjẹ́'wọ́ rẹ ni kò jẹ ki o kú ikú òjìji bí ti Balógun àti Séríkí.

**J. ÀWỌN Ọ̀DỌ́ ÌLÚ JOGBO:** Ṣe gudu-gudu méje yàyà mẹ́fà lórí ìdàgbàsókè ìlú Jogbo. Èyí mú kí ìrẹ́pọ̀ padà wá láàrín àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí.

**K. AMAWOMÁRÒ:** Òun náà jẹ ẹ̀dá ìtàn tí kò f'ọwọ sì ìwà ìbàjẹ́ rárá, ṣùgbọ́n nípa ìdún kokò mọ́'ni, ohun tí àwọn olóyè bá ń fẹ́ kí ó ṣe, naa ni òun náà ń ṣe. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn tí òtítọ́ bá f'oju hàn kí bẹ̀rù wọn. Òun náà wá lára àwọn bàbà-lawo tí ó búra fún àwọn olóyè tí wọ́n jẹṣẹbi nínú ọ̀rọ̀ ìlú Jogbo.

**L. ARÁPÁ-RE-GÁNGAN:** Jẹ ọkàn pàtàkì láti ìbẹ̀rẹ̀ ère orí ìtàgé náà títí di àwọn àkókò kan nínú ìtàn náà. Èyí tí a lè pè ní ẹ̀dá ìtàn 'Amúgbá-lẹgbẹ' nínú ìtàn náà.

Òun ni ẹni tí ó nífẹ sì 'Arẹsẹ-jabata' tí ó jẹ ọmọ'ba tí wọn pá bàbà àti ìyá rẹ láti ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn naa.

**M. BÀSÍRÁ:** Náà wà lára àwọn ẹ̀dá ìtàn tí òǹkọ̀tàn lọ gẹ́gẹ́ bí ìyàwó olóyè láàrin ìlú Jogbo. Òun náà ń tà ọjà nínú ọjà ìlú Jogbo, bákan náà.

**N. Ọ̀TÚN:** Wá lára àwọn tí ó fẹ́ kí ìlọsíwájú bá ìlú Jogbo pẹ̀lú ọba tuntun tí ó jẹ, tí orúkọ rẹ ń jẹ Bọ̀sípò. Ṣùgbọ́n àwọn olóyè tí wọn fẹ́ràn ijẹkujẹ, kò mú erongba rẹ wà sì ìmúṣẹ.

## ORÍ KẸTA

### 3.0. NÍPA ÌWÉ ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

Ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà jẹ́ ìwé eré-orí-ìtàgé tí ọ̀jọ̀gbọ́n "Akinwunmi Ishola kọ ní ọdún 1968".

Ẹfúnsetán Aníwúrà, obìnrin mẹ́ta

Adé -káyà-ó-já

Ẹ̀rùjẹ̀jẹ́ tí í fẹrú paléyá

Ẹfúnsetán Ọ̀kan-Ìbàdàn ọ̀kan

Abàyà gbàǹgbà tí í P'Olódùmarè lẹ́jọ́

Ọba-Òkè kò tètè dáhùn

Ẹfúnsetán gbéra láyé, ó lọ bá a lọ́run.

Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola mú ìtàn yìí láti inú ìtàn ìlú Ìbàdàn. Ní àkókò Ààrẹ Latosa ni Ẹfúnsetán ń ṣe ìyálóde Ìbàdàn. Àwọn ìwà Ẹfúnsetán Aníwúrà jọ Akinwumi Isola lójú jọjọ èyí ló mú sọ ìtàn náà di ère orí ìtàgé tí ó dúró gẹ́gẹ́ bí àpilẹ̀kọ ni ọdún náà.

### 3.1. ÀGBÉYÈWÒ ÈTÒ ÒṢÈLÚ INÚ ÌWÉ ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

Pàtàkì ni ètò òsèlú tàbí ìṣèlú jẹ́ ní Ilẹ̀ Yorùbá. Èyí sì bẹ̀rẹ̀ láti ilé ẹni, lọ sí agboolé, àdúgbò títí dé àwọn ìlú ńlánlà. Àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n pín ètò ìṣèlú Ilẹ̀ Yorùbá sì ọ̀nà mẹ́rin tí ó gbòòrò.

Èkíní ni ètò Ifẹ̀, Ìjẹ̀sà, Èkìtì àti Òndó tí wọn tẹ́lẹ̀ ìlànà Ifẹ̀. Èkejì ni ètò tì Ọ̀yọ́ tí wọ́n tẹ́lẹ̀ ìlànà Aláàfin Ọ̀yọ́. Ẹ̀kẹta ni ètò Ilẹ̀ Ìjẹ̀bú tí wọn tẹle ìlànà Ìjẹ̀bú- Òde, èyí tí ó ṣe ìkẹrin ni ti Ẹ̀gbá àti Èkó ti wọn tẹ́lẹ̀ ìlànà tí Ẹgbẹ́ ògbóni tí ó lágbára púpò.

Nínú ìṣe àpilẹ̀kọ yìí, ìlànà ètò ìṣèlú tí òǹkọ̀wé sàmúlò rẹ̀ ni ti Ọ̀yọ́. Ààrẹ Latosa, Ali Laluwoye, Láwoyin, Àjàyí àti Ayorinde jẹ́ àwọn Ìjòyè nígbà tí akọni obìnrin eré náà. Ẹfúnsetán Aníwúrà sì jẹ́ Ìyálóde Ìlú Ìbàdàn nígbà náà.

Nínú ìwé yìí, a rí í bí ajègbodò tí ń w'ẹ́ni kín'ra. Ẹfúnsetán fẹ́ kí gbogbo ayé dá bí òun ṣe dà. Ìbànújẹ́ orí rẹ t'o burú sọ ọ di wèrè, ó sì ń hùwà ìkà. Ṣùgbọ́n nígbà tí ìwà àìbìkítà yìí kún òṣùwọ̀n, ó tẹ kò dun'bẹ̀. Ààrẹ Latosa tí ó jẹ olórí ìlú rọ ọ l'óyè, ó sì di ẹni ìyà.

Lára àwọn ìwà ìbàjẹ́ tí Ẹfúnsetán ń wù ni pé Ẹrú-kérú tí ó bá gbìyànjú láti l'óyún tàbí fẹ ìyàwó pípa ni ó máa ń pá wọn sì àárín Ọjà tàbí ní iwájú ilé rẹ̀. Èyí tó mú Ààrẹ Latosa mú òun náà ni ẹrú tí ó sì í ṣíṣe nínú ààfin Ààrẹ Latosa. Lẹ́yìn-ọ-rẹyìn. Ìyálóde Ẹfúnsetán náà rò ó pé ikú yá j'ẹ̀sín lọ, ó gbé májèlé mì, ó sì kú.

## 3.2 KÓKÓ INÚ ÌWÉ "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

Àwọn kókó tí ó jẹyọ nínú ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà ni wọ̀nyíi

a. Ìwà àgbèrè sise

b. Ìwà ìkà

d. Isẹ̀ ọkọ ṣíṣe

e. Ìwà ìpànìyàn

ẹ. Ìwà àìlóòótọ́

**1. ÌWÀ ÀGBÈRÈ ṢÍṢE:** Jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú kókó tí ó wà nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ" tí òǹkọ̀wé fẹ́ jẹ́ kí a mọ̀. A ríi Àwẹ́ró àti Itawuyi tí ó jẹ́ ẹ̀dá ìtàn nii òǹkọ̀wé gbé ìwà àgbèrè ṣíṣe wọ̀ lọ́rùn. Àwọn ènìyàn wọ̀nyí jẹ́ ẹrú ni ilé ìyálóde Ẹfúnsetán. Lẹ́yìn-ó-rẹyìn Àwẹ̀ró lóyún, èyí ló ṣokùnfà ikú òjìji fun-un. Nítorí pé Ẹrú-kẹ́rú tí ó bá l'óyún ní ilé ìyálóde ọ̀ọ̀run alákeji ni yóò ti bíi.

**2. ÌWÀ ÌKÀ:** Ọ̀kan pàtàkì nínú kókó tó jẹ́yọ nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ" tí òǹkọ̀wé fẹ́ jẹ́ kí a mọ́. Irú ìwà yìí ni òǹkọ̀wé gbé wọ Ìyálóde Ẹfúnsetán fún ra rẹ̀. Èyí ló mú tí kò gbà ẹ̀bẹ̀ ẹrúbìnrin rẹ̀ tí ó ní oyún, tí orúkọ rẹ ń jẹ Àwẹ̀ró. Gbogbo ọ̀nà ti Itawuyi mọ̀ láti ri pé Ìyálóde gba ẹ̀bẹ̀ òun ni kò bọ́ sì títí tí Ìyálóde Ẹfúnsetán fi ṣe'kú pa Àwẹ̀ró ni ọjọ́ ọjà ni ìta gbangba ilé rẹ̀.

**3. IṢẸ́ OKO ṢÍSE:** Èyí jẹ kókó mìíràn tí òǹkọ̀wé fẹ́ kí a mọ̀ nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ" Irúfẹ́ iṣẹ́ yìí kò fẹ́ sì ẹ̀dá ìtàn kan nínú ìwé náà tí òǹkọ̀wé kò sàì gbé wọ lọ́rùn nínú ìwé náà. A lè tọ́ka èyí sì Ìyálóde fún ara ẹ àti Ogunjimi akọ̀pẹ pẹ̀lú Akíngbadé. Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A rí Ogunjimi níbi tí ó ti ń ṣiṣẹ́ nínú oko ọ̀pẹ rẹ tí àwọn ẹrú ìyálóde pè ní ọ̀lẹ, èyí ló mú wọn pe Ẹfúnsetán tí ó sì pàṣẹ pé kí wọ́n lu Ògúnjìmí akọ́pẹ títí tí ẹ̀mí rẹ fi bọ́.

**4. ÌWÀ ÌPÀNÌYÀN:** Jẹ́ ìwà tí ó ṣe kókó jùlọ nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ" tí òǹkọ̀wé gbé wọ ẹ̀dá ìtàn "Ẹfúnsetán Aníwúrà" wọ̀ l'ọ́rùn nígbà tí ó wà ní ipò gẹ́gẹ́ bí Ìyálóde Ìlú Ìbàdàn. Èyí ló mú kí ó ṣe òfin wí pé ẹrú-k'ẹ́rú obìnrin tàbí ọkùnrin rẹ tí ó bá fẹ́ ìyàwó tàbí kí ẹrúbìnrin l'óyún pípa ni yóò pá wọn s'ọnù.

**5. ÌWÀ ÀÌLÓÒÓTỌ́:** Jẹ́ ìwà tí ó ṣe kókó nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ" tí òǹkọ̀wé gbé wọ àwọn ẹ̀dá ìtàn bíi 'Ẹrúkùnrin Ìyálóde. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ wí pé ẹlẹ́ran ara kò ní sàì máa hùwà bí Ẹlẹ́ran ara, nítorí pé àwọn jẹ́ ẹrú èyí mú kí wọ́n parọ́ mọ́ Bàbá Ògúnjìmí akọ̀pẹ nínú oko rẹ wí pé ó lọ jí ọ̀pẹ Ìyálóde; Nínú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni wón ti bẹ̀rẹ̀ sí ní lu títí tí ó fi kú.

## 3.3 ÀHUNPỌ̀ ÌTÀN NÁÀ NÍ ṢÓKÍ

Ìwé eré orí ìtàgé "Ẹfúnsetán Aníwúrà" dá lé Ìyálóde, Adẹ́tutù, Itawuyi àti Latosa tí a lè tọ́kasí gẹ́gẹ́ bí olú ẹ̀dá ìtàn. Ní orí kìn-ín-ní a rí bí àwọn ẹrú Ìyálóde ṣe ń ṣiṣẹ́ tí wọ́n sì ń tàkurọ̀ṣọ láàrin ara wọn, kò-pẹ́-kò-jìnnà ni ọ́kan lára wọn tí orúkọ rẹ ń jẹ Osuntunde sọ fún gbogbo wọn wí pé Ìyá ń bọ̀. Bí Ìyálóde ṣe wọlé ní o n bèrè lọ́wọ́ wọn wí pé iṣẹ́ wo ni wọ́n ń ṣe, bayi ni ó bẹ̀rẹ̀ si ni fi Ìyà jẹ wọ́n, tí ó sì sọ àwọn ẹrúkùnrin mọ́lẹ̀ bí ẹran.

Nínú orí kejì ni òǹkọ̀wé tí jẹ ki a rí Ilé Ìyálóde tí ẹnìkan kànlẹ̀kùn. Ìyálóde bẹ̀rẹ̀ si ni bínú wí pé tani kò jẹ kò òun sùn, orúkọ ẹni náà níi Akinkunle, tí ó wà láti sọ fún Ìyálóde pé ara ọmọ òun kò yà. Báyìí ni Ìyálóde bẹ̀rẹ̀ si sọ̀rọ̀ sì wí pé kí ni ó fẹ́ kí òun ṣe.

Lẹ́yìn-ó-rẹyìn tí Akinkunle lọ tán ni Ìyálóde bẹ̀rẹ̀ si ni sọ̀rọ̀ ni òun nìkan pé ọmọ mélòó ni Ọlọ́run fún òun ti o jẹ ki Òun máa ronú. Nínú èyí ni ó ti pinnu wí pé òun á fi ojú ẹrú rí màbo.

Orí kẹta ni òǹkọ̀wé ti jẹ́ kí á rí Gbọ̀ngàn Latosa. Latosa àti àwọn Ìjòyè rẹ jókòó nínú ọláńlá wọn. Akígbe ń ki Ààrẹ Latosa ni mẹsan-mẹwa, pẹ̀lú àwọn ìjòyè rẹ. Latosa kí gbogbo àwọn Ìjòyè ó sì ṣàlàyé ẹjọ́ tí Latinwo mú wá wí pé àwọn ẹrúkùnrin Ìyálóde tún lu ọkùnrin akọ̀pẹ tí orúkọ rẹ ń jẹ Ogunjimi títí tí ẹ̀mi fi bọ́ lára rẹ. Níbi yìí ni wọn ti pinnu láti kojú Ìyálóde ìdí tí ó fi ń lọ agbára l'ọ́nà àìtọ́.

Orí kẹrin ni òǹkọ̀wé tí jẹ ki a rí Adétutù ọ̀kan nínú àwọn ẹrú Ìyálóde tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ di irun orí rẹ̀, Òun àti Itawuyi bẹ̀rẹ̀ si ni tàkurọ̀ṣọ lórí ìfẹ́ tí Itawuyi ni sì Adétutù. Òǹkọ̀tàn tún jẹ́ kí a mọ̀ pé Itawuyi tí fún Adetutu l'óyún , èyí tí ó mú kí àwọn ẹrú tí ó kú fura si Adétutù ní pa ìṣesí rẹ lẹ́nu iṣẹ́. Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ló fà Ìjà láàárín Itawuyi àti Àkànó. Lẹ́yìn-ó-rẹyìn ọ̀rọ̀ de etí Ìyálóde wí pé Adétutù tí l'óyún .

Orí Kàrún-un: òǹkọ̀tàn jẹ́ kí a rí ilé Ìyálóde tí ó ń s'àfihàn ilé àwọn ẹrú tí wọn ń sọ nípa Adétutù tí ó ní oyún. Àwọn ẹrú náà nii Àwẹ̀ró àti Itawuyi; lẹ́yìn èyí ni Osuntunde pe ọ̀rẹ́ rẹ wí pé kí ó wá jẹ ìṣù.

Orí kẹfà ni òǹkọ̀wé tí jẹ ki a rí Ilé Akíngbadé àti ìyàwó rẹ̀ tí wọ́n wọlé. Òǹkọ̀wé jẹ́ kí a mọ̀ pé àwọn méjéèjì ń gbára dì láti jẹun ní Ogunniyi náà wọlé, wọn si jìjọ jẹ́ ọbẹ̀ akátá tí pàkúté Akingbade pá ni oko rẹ̀. Nínú ìtàkurọ̀sọ wọn ní wón ti sọ ti ẹrúbìnrin Ìyálóde tí ó ní

Oyún; orúkọ rẹ̀ ni Adétutù. Lẹ́yìn-ó-rẹyìn wọ́n pinu pé Ẹrú-kẹ́rú kò gbọ́dọ̀ sọ̀rọ̀ náà síta.

Orí keje ni òǹkọ̀wé tí jẹ́ kí a mọ̀ pé Ìyálóde ti gbọ́sí ọ̀rọ̀ náà. Ìdí nìyí tí ó fi pe Itawuyi láti lọ sí fún àwọn ẹrú tí ó kú wí pé ẹnikẹ́ni nínú wọn kò gbudọ jáde. Báyìí ni Ìyálóde àti Àjílé wọlé láti wá bá àwọn ẹrú rẹ̀ sọ̀rọ̀, wí pé òun ti gbọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ náà, ó sì pe Adétutù gẹ́gẹ́ bíi ìṣe rẹ̀ ó dà jọ ikú fún Adẹ́tutù.

Orí kẹjọ ni òǹkọ̀wé jẹ́ kí á rí àwọn àgbàlagbà tí wọ́n ń kànlẹ̀kùn ní Ilé Ìyálóde, òǹkọ̀wé tẹ̀ síwájú pé ọ̀rọ̀ nípa Adẹ́tutù ni wọ́n wá bá Ìyálóde pé kí ó fi ori ji ọmọ náà nítorí pé àbúrò rẹ ni ó ṣe àṣemáṣe náà. Ṣùgbọ́n Ìyálóde fi ààké kọri pé òun kò ní gbà àti pé inú àgbàlá rẹ̀ ni ó ti fẹ́ pá Adẹ́tutù tẹ́lẹ̀, àmọ́ ni báyìí ìta gbangba ni òun yóò ti pá. Báyìí ni Ìyálóde pàṣẹ kí wọ́n lọ mú Adẹ́tutù wá sí ìta iwájú ilé rẹ, tí abẹ ni lórí sì ṣe iṣẹ́ ọwọ rẹ̀.

Orí Kẹ̀sán ni òǹkọ̀tàn tí jẹ́ kí a rí àwọn èrò ọjà tí Wọ́n ń sọ ní pá bí ọjà ṣe rí, kò pẹ, kò jìnà ni ọmọbìnrin kan sáré wọnú ọjà, tí ó ń sọ ohùn tí ojú rẹ rí ní iwájú Ilé Ìyálóde. Báyìí ni gbogbo ọjà túká láti lọ wo ìṣẹ̀lẹ̀ náà.

Orí Kẹ̀wá ni òǹkọ̀wé tí jẹ́ kí á mọ nípa ìgbésẹ̀ Ààrẹ Latosa lórí ìwé Ẹfúnsetán Aníwúrà tí ó ń pa kúkúrú àti gígùn láàrín ìlú. Ààrẹ Latosa sọ fún aláago wí pé kí ó lọ sọ fún ìyálóde Ìbàdàn, kí ó fi ìlú sílẹ̀. Bí bẹ̀ẹ̀kọ́ ìlú ń bọ̀ láti wá jẹ lé rẹ run.

Ní orí kọkànlá ni a tí rii àwọn ẹrú ìyálóde tí wọ́n jíròrò lórí ikú tí ó pá ọ̀kan lára wọn. Àwẹ̀ró Osuntunde àti Itawuyi ń gbìmọ̀ pọ̀ lórí bí wọ́n ṣe le pá ìyálóde Ẹfúnsetán Aníwúrà. Nínú ìpinnu wọn ní láti fi májèlé sínú oúnjẹ Ìyálóde. Lẹ́yìn tí Moyọ̀ ọ̀kan lára àwọn ẹrúbìnrin ìyálóde gbé oúnjẹ Ìyálóde wọlé ní Àwẹ̀ró ní kí ó máa lọ, báyìí ni Àwẹ̀ró ṣe fi òògùn sínú oúnjẹ náà.

Lẹ́yìn-ó-rẹyìn ni Ìyálóde fúra pé májèlé wà nínú oúnjẹ náà, báyìí ni Ìyálóde pe Àwẹ̀ró pé kí ó wá jẹun, ṣùgbọ́n Àwẹ̀ró bẹ̀rẹ̀ sí ní gbọ̀n, Ìyálóde kò gbà fun rárá títí tí ó fi agídí kí ọbẹ̀ bọ ẹnu Àwẹ̀ró. Àwẹ̀ró kú Itawuyi s'áré wọlé pẹ̀lú àdá lọ́wọ́ láti bẹ orí Ìyálóde, ṣùgbọ́n kò ṣiṣẹ́ fún-un. Ìyálóde wá pàṣẹ fún Itawuyi láti jókòó silẹ kí ó sì máa jẹ oúnjẹ náà fún ra rẹ̀.

Kò pẹ, kò-jìnnà ni ariwo ńlá sọ tí ọ̀kan nínú àwọn ẹrú Ìyálóde sáré wọlé láti sọ fún Ìyálóde pé gbogbo àwọn ará ìlú ti ń bọ̀ láti k'ọjú ìjà sí Ẹfúnsetán Aníwúrà. Ààrẹ Latosa sa gbogbo agbára rẹ̀ pẹ̀lú àwọn Ìjòyè tí ó kù, wọn si rii pé wọ́n mú Ìyálóde.

Ní Ìran Kejìlá ni ọ̀nkọ̀tàn ti jẹ́ kí á rí Ẹfúnsetán Aníwúrà ni iwájú ilé Latosa tí ó ń gbálẹ̀ lọ́wọ́, ṣùgbọ́n tí ó ń dá s'ọ̀rọ̀. Látàrí bí Latosa ṣe mú òun Ìyálóde tí ìlú Ìbàdàn. Ẹfúnsetán Aníwúrà pa ọkàn rẹ̀ pọ̀ tí ó sì ṣe bẹ́ẹ̀ gbé òògùn (májèlé) jẹ́ fún ra rẹ̀.

## 3.4 ÀPẸ́JÚWE ÀWỌN Ẹ̀DÁ ÌTÀN INÚ ÌWÉ ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

Onírúurú ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ni ó wà nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ " ṣùgbọ́n àwọn tí ó ṣe kókó nínú wọn ni wọ̀nyí.

Ìyálóde Ẹfúnsetán Aníwúrà, Adẹ́tutù, Àwẹ̀ró, Itawuyi, Latosa, Ògúnjìmí, Osuntunde, Àjílé, Akínkúnlé, Àjàyí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**a. ÌYÁLÓDE ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ:** Jẹ́ ẹ̀dá ìtàn kan pàtàkì tí òǹkọ̀wé gbé ìwà ọ̀dájú wọ̀ lọ́rùn láti ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn náà; A rí bí ó ṣe ń lọ àwọn ẹrú rẹ ni lò kú lọ. Lára àwọn òfin Ìyálóde ni pé àwọn ẹrúbìnrin rẹ kò gbọdọ̀ l'óyún bèlèǹtàsé ọkùnrin wọn kò gbọdọ̀ ní ìyàwó. Èyí tí ó bá dán wò pípa ni yóò pa wọ́n.

Àsẹ̀yìn-wá-àsẹ̀yìn-bọ̀ ọwọ́ tẹ Ẹfúnsetán Aníwúrà tí òun náà sì padà di ẹrú nílé Latosa, kí ó tó di pé ó gbé májèlé jẹ fún ra rẹ̀ tí ó sì kú pátá-pátá.

**b. ADẸ́TUTÙ:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn kan pàtàkì nínú ìwé "ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ", òun ni ọ̀ǹkọ̀tàn gbé ìwà ẹrú wọ̀ lọ́rún láti ìbẹ̀rẹ̀ itàn naa títí dé òpin ìtàn. Adẹ́tutù ni ẹrúbìnrin Ìyálóde tí ó ṣe àṣemáṣe pẹ̀lú ọ̀kan nínú àwọn ẹrúkùnrin tí orúkọ rẹ ń jẹ́ Itawuyi, tí ó sì l'óyún ni pá aṣẹmáse náà.

Gbogbo ìgbìyànjú, Adẹ́tutù àti Itawuyi lórí oyún inú rẹ̀ wí pé kí Ìyálóde má mọ̀ si ni ó já sí pàbó. Ìyálóde s'ekú pa Adétutù ni ìta gbangba ilé rẹ̀.

**d. ÀWẸ̀RÓ:** Jẹ́ ẹ̀dá ìtàn tí òǹkọ̀wé gbé ìwà ẹrú wọ̀ lọ́rùn. Òun náà jẹ ọ̀kan lára àwọn ẹrúbìnrin Ìyálóde Ẹfúnsetán Aníwúrà. Óun ni ẹni tí ó fi májèlé sínú oúnjẹ Ìyálóde tí àṣírí rẹ̀ sì tú, Ìyálóde fun ní ọbẹ̀ náà lá pẹ̀lú agídí. Èyí ni ó mú Àwẹ̀ró náà di èrò ọ̀run alákeji.

**e. ITAWUYI:** Òun ni ẹni tí ó fún Adétutù l'óyún tí Ìyálóde sì ṣe ikú pa Adétutù nítorí pé ó l'óyún. Itawuyi gbìyànjú láti gba ẹ̀mí Ìyálóde ṣùgbọ́n kò rìí ṣe rárá. Àsẹ̀yìn-wá-àsẹ́yìn-bọ́ Itawuyi bọ́ lọ́wọ́ Ẹfúnsetán Aníwúrà nígbà tí àwọn ará ìlú tí ń k'ógun bọ́ wá sí ilé Ìyálóde Ìbàdàn. "Ẹfúnsetán Aníwúrà".

**ẹ. LATOSA:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn kan tí ó ṣe pàtàkì nínú ìtàn náà. Òun ni Ààrẹ ìlú Ìbàdàn nígbà ayé rẹ, òun gan-an ni ó mú Ìyálóde Ẹfúnsetán Aníwúrà l'ẹ́rú lọ sí àgbàlá rẹ̀ lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìjà láàrin àwọn méjéèjì.

**f. OGUNJIMI:** Òun ni bàbá akọ̀pẹ tí àwọn ẹrú Ìyálóde parọ́ mọ́ wí pé ó jí ọ̀pẹ Ìyálóde, tí wọ́n sì fi ìyà jẹ ẹ́ títí tí ẹ̀mí rẹ̀ fi bọ́ mọ́ wọn lọ́wọ́. Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí bí àwọn Ìjòyè nínú tí wọn fi ṣe ìpàdé. Nínú èyí ni Ààrẹ Latosa tí wá pinnu láti k'ojú Ìyálóde. Ìṣẹ̀lẹ̀ ikú Ògúnjìmí dùn àwọn Ìjòyè ìlú àti àwọn mọ́lẹ̀bí rẹ̀.

**g. OSUNTUNDE:** Jẹ ọkan lára àwọn ẹrú Iyalode tí ó jẹ ọ̀rẹ́ fún Itawuyi tí ó fún Adetutu l'óyún. Òun wà lára àwọn ẹrú tí Latosa dá sílẹ̀ lẹ́yìn tí wọn mú Iyalode Ẹfunsetan Aniwura l'ẹru.

**gb. ÀJÍLÉ:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn mìíràn tí òǹkọ̀wé lò nínú ìtàn Ẹfúnsetán Aníwúrà, òun ni ọ̀rẹ́ ìyálóde tí ó súmọ́ pẹ́kí-pẹ́kí. Ìyálóde náà ń fún ní ǹǹkan bíi Aṣọ, Owó, Oúnjẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àjílé mọ ìwà ọ̀rẹ́ rẹ̀ dáadáa, ìdí nìyí tí ọ̀rọ̀ wọn fi jọra.

**h. AKÍNKÚNLÉ:** Jẹ ẹ̀dá ìtàn tí ó ṣe pàtàkì nínú ìtàn náà. Òun ni àbúrò Ìyálóde Ẹfúnsetán Aníwúrà. Òun ni àwọn ẹrú Ìyálóde rọ̀ pe ó le gba àwọn sílẹ̀ lọ́wọ́ ikú, wí pé kí ó dúró gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó fún

Adétutù l'óyún, ṣùgbọ́n Ìyálóde tí ó jẹ́ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ kò gbà ọ̀rọ̀ náà sì l'ẹ́nu.

**í. ÀJÀYÍ:** Òun ni ó wà lára àwọn olóyè Ìlú Ìbàdàn nígbà tí Latosa pàṣẹ wí pé kí wọ́n lọ k'ojú Ẹfúnsetán Aníwúrà. Òun gan-an ni ó kọ́kọ́ gbọ́ ikú Ògúnjìmí akọ̀pẹ tí àwọn ẹrú Ìyálóde lù pa sìí ọ̀nà oko.

## ORÍ KẸRIN

## 4.0 NÍPA ÌLÒ ÈDÈ ẸFÚNSETÁN ANÍWÚRÀ

Gẹ́gẹ́ bí Awóníyì (1974) ti sọ, èdè ni àkójọpọ wọ̀rọ́hùn tí ó di ọ̀rọ̀ tí à ń sọ tàbí kọ láti mú kí èrò ọkàn wa hàn sí ẹnìkejì wá. Káàkiri àgbáyé ni a ti ń lọ èdè gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó péye, àbímọ́ tàbí àdámọ́ sì ni gbogbo àwọn ẹ̀yà ara tí à n lò láti fi sọ tàbí kọ èdè fún ènìyàn bí àpẹẹrẹ: ahọn, ètè, ẹnu, tàn-án-na, ọwọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ọmọ bá ṣe ń dàgbà sì ni eya ara wọ̀nyí pò ṣe máa wúlò fún ipede lọ́nà tí ó já gaara, àyàfi ẹni tí ó bá ní àléébù lára àwọn afipe wọ̀nyí ni èdè lè di ẹti fún.

Ọjọgbọn Olatunji (1982) náà kíyèsí bí èdè ṣe ṣe pàtàkì sì nígbà tó sọ pé "èdè ni olóòtú gbogbo etekete tí a ń pá nínú lítíréṣọ̀". Ó tún tẹsiwaju pé "ìlò èdè ni ọ̀nà àrà máa ń mú ìṣe ọnà lítíréṣọ̀ ni àbájáde tó péye".

Ohun tí a rí fà yọ l'oke yìí ni pé ìyàtọ̀ wá láàárín èdè tí òǹkọ̀tàn tàbí òńkọ̀wé lo àti bí òǹkọ̀tàn ṣe lo èdè nínú ìṣe rẹ èyí wá ní ìbámu pẹ̀lú ohun ti Iraugott àti Pratt (1980) so pé ìyàtọ̀ wá láàárín èdè àti ìsọwọ́lò èdè òǹkọ̀tàn tàbí òǹkọ̀wé eré oníse àti eré orí ìtàgé. Wọn ní èdè ni àwọn èròjà lingisiiki náà. Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé èdè kan náà ni àwọn onkọtan tàbí onkọwe ìtàn aroso Yorùbá ń lò, sì bẹ isowolede ẹnikọọkan lọ yàtọ̀.

Ọ̀nà tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola gba lọ èdè nínú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúra tún yàtọ̀ sí bí ó ṣe fi ọ̀rọ̀ sísọ s'ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtàn

tí ó ṣe àkójọ wọn nínú fììmù àgbéléwò "Agogo Ẹ̀ẹ̀wọ̀" ìdí nìyí tí a ní láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà èdè wọ̀nyí ni ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú ìwé eré oníse "Ẹfúnsetán Aníwúrà ". Díè lára àwọn ọ̀nà èdè tí ó jẹyọ nínú Ẹfúnsetán Aníwúrà ni.

**A. ÒWE:** Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ wí pé òwe ni ẹṣin ọ̀rọ̀, èyí ló mú kí àwọn òǹkọ̀tàn alatinuda máa sàmúlò òwe nínú onírúurú ìtàn àròsọ, láti fi mú òǹkọ̀tàn tàbí onworan l'ọ̀kan sókè àti láti lè ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa ohùn tí wọn ń sọ. Àpẹẹrẹ èyí ni wà nínú ere onise "Ẹfúnsetán Aníwúrà".

"èkúté ó rẹni fẹjọ́ ológbò sùn"

Ìtùmò èyí ní pe ẹní tí ó bá juniḷọ, lè juninù.

"òṣìṣẹ́ wá l'orun, ẹni máa jẹ ẹ nkọ?

Eleyi wá ní booji.

Ìtumọ̀ èyí ni pé ẹni tí ó bá ní agbára lórí ẹni lè lọ agbára láti ṣe òun ti o ba fẹ.

Òwe mìíràn ni.

“Bí irungbọ̀n alágbàse ṣe gùn tó,

Ẹni tí ó gbóko fún un lọ̀gá rẹ.

Ìtumọ̀ èyí ni pé ẹni tí ó uni lọ, lè lọ agbára lórí ẹnì. Òwe mìíràn tún ni

“Àgbàlagbà kì í wà lọ́jà, kí orí ọmọ titun wọ́.

Ìtumọ̀ èyí ni pé àgbà kì wà níbìkan, kí ìbàjẹ́ máa ṣẹlẹ̀ ni bẹ́ẹ̀.

Òmíràn tún ni:

"Bí ewúré ẹni ba sa wọlé alagidi

Ẹnu ọ̀nà ni a ti í padà sẹyin.

Ìtumọ̀ òwe yi ni pé, ẹni tí ó ní ìwà ara ẹni nìkan, kò sì ohun tí wọn lé bá sọ kò ní gbọ rárá.

Òwe mìíràn tún wáyé níbi Fafenwa àti Iyalode jọ ń sọ̀rọ̀ lórí oyún tí ó wà nínú Adetutu. Wí pe

"Iṣu ẹni, òun na ni í sii tí ọwọ ẹni bọpo"

Itumọ èyí ni pé ọmọ ẹni náà ni'se nǹkan ti a o si fara mọ. Òmíràn tún jẹyọ bákan náà

"Ẹranko ilé náà nii fi ojú dọdẹ"

Itumọ èyí ni pé ẹni tí ó bá sunmọ ni náà lè ṣe bo se fẹ́.

'Bí a bá ní kí a bẹ igi ni igbo

Ó ṣe é ṣe kí a bẹ ènìyàn'.

Èyí túmọ̀ sí pé kí a ronú lórí òun ti a ba fẹ́ ṣe.

Òwe mìíràn tún ní, ní ibi tí Akingbade àti Iyalode tí sọ̀rọ̀ nípa Adetutu wí pé kí ó f'ori jí ọmọ náà, ṣùgbọ́n Iyalode kọ jalẹ ó wà pá òwe pe:

"Itakun tí ònì kẹrin má kaná,

Ẹfunsetan, t'oun t'erin lọ ń lọ".

## B. ÀFIWÉ TÀÀRÀ

**ÀFIWÉ TÀÀRÀ:** Jẹ́ ọkan nínú àwọn àpẹẹrẹ ọ̀nà isowolede tí ó wà nínú ẹgbẹ́ àwòrán lábé èyí á máa ń fi nǹkan méjì tó jọra wé ara wọn. Ó ní àwọn ọ̀rọ̀ ìṣe tí a ń lò nínú èdè Yorùbá láti fi nkankan wé ara wọn. Ọ̀rọ̀ Ìṣe tí a maa n sàmúlò ni "Bíi".

Tí a bá wo onírúurú àwọn òǹkọ̀tàn ni ó sábà máa ń sàmúlò àfiwé tààrà yìí nínú àwọn ìtàn àròsọ wọn. Fún àpẹẹrẹ wọn lé kọ pe

"Odudu bíi ẹbọra"

"Oníwàjú gbàǹgbà bíi oya lagi"

"Iwájú rẹ bíi ọpalamba"

"Ọmọbìnrin yìí dára bíi egbin" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## D. ÀFIWÉ ẸLÉLỌ̀Ọ́

**ÀFIWÉ ẸLÉLỌ̀Ọ́:** Jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ọ̀nà ìsowọ́lede. Nínú irú àfiwé bẹ́ẹ̀ dípò kí nǹkan méjéèjì tí a fi wé ara ó fi ara hàn orúkọ nnkan kejì ni a ó fi pe nǹkan kín-ín-ní.

Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́ tún pín sí ọ̀nà méjì. A ní mẹtonimi àti mẹtafọ.

Mẹtafọ ni pípé nǹkan kan ni orúkọ míràn, orúkọ mììràn tí a ó wà fún un gbọ́dọ̀ na a mú, ó gbọ́dọ̀ ni àwọn àbùdá o lórúkọ bẹ́ẹ̀ .

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ tí a bá pè ẹnìkan nii "Akọ ajá" Yorùbá mọ akọ ajá mọ ìrìn àrè nítorí pé ó máa ń tẹ̀lé àbọ̀ ajá kíri. Bí wọn ba ti wá pé ẹnìkan ni akọ ajá, a ó ti mọ̀ pé onirinkirin ni iru ẹni bẹ́ẹ̀. Tàbí tí wọn na si pe ẹnìkan ni

"Ọ̀fọ́n-ọ̀n" A ó ò tí mọ pe olè ni iru ẹni bẹ́ẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní ti mẹtonimi, nínú irú akanlo èdè ayàwòrán yìí a kì í kan fi orúkọ nǹkan kejì pé nǹkan kin-in-ni ṣùgbọ́n a máa ń wo àbùdá tàbí adamọ náà fi pè é. Wọn máa ń pe aba wáyé ọkùnrin ní "Ile-ise".

Bákan náà ni wọ́n sì ń pe oluransọ ni "Sabẹ́rẹ́dowó". Yorùbá tún lè lọ afiwe ẹlẹlọ ọ fún ìgbà mẹtẹẹta nílé ayé.

Àárọ̀ túmọ̀ sí ìgbà ọmọdé. Bákan náà Ọsan jẹ́ ìgbà tí ènìyàn wá ní ògiri pá, nígbà tí alẹ jẹ ìgbà ogbó.

Bákan náà àárọ̀ ọjọ ni a máa ń dá ẹtu ni fìlà èyí ni irun dúdú tí ó bo orí wa, amọ ọsan ni a máa ń dá Adìrẹ èyí ni igba ti irun ewú kọọkan ń wá ní ààrín, irun funfun tó sì jẹ pe ọwọ́ alẹ là máa ń dá aṣọ Àlá eérú yóò ti gba gbogbo orí wa.

## E. ÀWÍTÚNWÍ

**ÀWÍTÚNWÍ:** jẹ́ orísìí àkànlò èdè ayàwòrán kan nínú èyí tí asàfọ̀ tí máa ń ṣe àwítúnwí kókó ọ̀rọ̀ kan bí ìgbà mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Ohun tí a ń ṣe àwítúnwí rẹ yìí lè jẹ́ odidi ọ̀rọ̀ kan ó tún lè jẹ́ odidi gbólóhùn. Bákan náà ni a lè ṣe awitunwi òye tàbí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀.

Orísìírísìí ìṣe ni awitunwi ń ṣe nínú ọ̀rọ̀. Lọ́nà kín-in-ni, ó ń jẹ ki a mọ ibi tí ó ṣe pàtàkì nínú ọ̀rọ̀ tí a ń sọ nípasẹ̀ atẹnumọ, ṣe àwọn Yorùbá tí parí ọ̀rọ̀ wí pé "Bí alagbẹdẹ bá ń lu ojú kan ni ara irin, a jẹ pe irin náà ni àmì ni. Ise mìíràn tí awitunwi tún ń ṣe ní pe o n jẹ ki o rọrùn láti mú àwọn ìlà tàbí gbólóhùn kan sórí nínú ewì. Ìṣe kẹta tí àwítúnwí ń ṣe ní pe o n jẹ ki o rọrùn fún àwọn olùwòran láti lọwọ nínú ìṣe akéwì pàápàá bí ó bá ṣe orin.

Gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀tàn alátinuda tí ó lè ronú jinlẹ̀, èyí ló mú Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola náà sàmúlò ọnà èdè nínú eré oníse "Ẹfúnsetán Aníwúrà." náà. Èyí jẹyọ níbi tí Ìyálóde tí ń bá àwọn ẹrú wi;

Iṣẹ́ làá ṣe

Iṣẹ́ là á ṣe

Òmíràn tún wáyé níbi tí àwọn ẹrú náà tí ń sọ̀rọ̀ Àwẹ̀ró ni.

Èmi Awẹro Ògún, èmi obìnrin na

Èmi ọmọ onílé ọlọ́nà, ọmọ onílẹ̀

Èmi ìbàdí-àrán, èmi ìbàdí ìlẹ̀kẹ̀.

Irúfẹ́ àwọn àwítúnwí yìí ni a lè pè ní: Àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí í

Èmi x3

Ọmọ x3 àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bákan náà irúfẹ́ ọ̀nà èdè yìí tún jẹyọ nígbà tí Akinkunle àbúrò Ìyálóde wá bá ní ilé rẹ l'owurọ kùtùkùtù. Iyalode lọ d'ahun pe:

Taa ni

Taa ni kí í gbele tìrẹ tí yóò fi wàhálà pá mi?

Taa ní yio fà abogunde mi yà.

"Taa ni" nínú gbólóhùn yìí jẹ awitunwi, òmìran tún nii.

"Ìwọ wo ni, ìwọ wo ni kii gbele rẹ?

Ìwọ wo ni ile kí mọ bá sórí ẹni?

Ìwọ wo ni arìnru, ìwọ oníyẹ̀yẹ́ wo ni?"

Kókó ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sì Ìyálóde pẹ̀lú gbólóhùn òkè yìí ni pé Ìyálóde kò sì ọmọ bí, ṣùgbọ́n Akinkunle wá dágbére fún pé òun ń lọ wo ọmọ òun ni òkè ẹgan.

A tún rii àwítúnwí odindi gbólóhùn tí ó jẹyọ níbi pé àṣírí wọn tí tú bayi.

Ọkàn lára ẹrúbìnrin Ìyálóde tí ṣe asemásel, ó sì ti l'oyun. Èyí jẹyọ pe:

"Oníyẹ̀yẹ́ sebí òun lè mú ú jẹ"

"Oníyẹ̀yẹ́ sebi òun lè mú ú jẹ"

Àwítúnwí odindi gbólóhùn mìíràn tún wáyé níbi tí àwọn àgbààgbà ìlú tí ń bẹ Ìyálóde lórí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ yii

"Èyí tí ó bá wù yín, kí ẹ se

Èyí tí ó bá wù yín, kí ẹ wí".

Ní ìparí a rí àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ níbi tí àwọn èrò ọjà tí ń sọ̀rọ̀ ni pá ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ ni ojú ọ̀nà ilé Ìyálóde wí pe:

'orí mi ò! Orí mi ò. Yé yé yé!

Kí lo dé, Kí lo rí tó o?

Orí mi ò! Yé! Yé! Yé!

Ọ̀rọ̀ ti a se àwítúnwí rẹ̀ ni ìgbà mẹ́fà nínú gbólóhùn yìí ni (Yé! Yé! Yé!) ti o jẹ àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀.

## Ẹ ÀSỌRÉGÈÉ

Lílọ akanlo èdè ayàwòrán yìí ni kí a ṣàpèjúwe ẹnìkan tàbí kí a ròyìn ìṣẹ̀lẹ̀ kan ju bí ó ṣe yẹ lọ. Sise àpèjúwe tàbí ìròyìn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ yìí máa ń yà àwòrán ohun náà sínú ọkàn olùgbọ́, èyí yóò sì jẹ ki o túbọ̀ yé e sii. Irú èdè báyìí wọn ń pè ní àsọdùn tàbí aponpo tẹ́lẹ̀. Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola náà ṣe àmúlò èyí nínú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà, fún àpẹẹrẹ:

"Àní mo rí kaninkanin tó tóbi tó jesin lọ

“Mo rí kamodu tó gùn tó jeniyan.

Àsọrégèé inú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí ni pé kaninkanin jẹ́ ẹ̀kẹ kékeré, ṣùgbọ́n tí kò ní ara debi pé yóò ju esin lọ. Èyí ni òǹkọ̀tàn lọ láti fi ìwà àti ìṣe rẹ mọ ènìyàn lọrun.

Àpẹẹrẹ mìíràn nii.

"Ọmọ èwe kan ni mo pè

"Ìgbà èwe ni n jẹ mi lójú ọlọ

Àsọrégèé ibẹ ni pé kó rọrùn kí ènìyàn fẹ́ gùn ère kan ṣoṣo kí ẹyọ kan náà di ìgbà lójú ọlọ.

## F. ÌFOHUNPÈNÌYÀN

Nínú àkànlò èdè ayàwòrán yìí ni òǹkọ̀tàn alatinuda tí má ń sọ̀rọ̀ nípa nnkan ti ko ni èmí tàbí tí kì í ṣe ènìyàn bí ẹni pé ènìyàn ni. Gbígbé ìsesí tàbí ìhùwàsí ènìyàn wọ ohun aláìní èmí ni a mọ sì ìfohunpènìyàn. Fún àpẹẹrẹ nínú eré oníse Ẹfúnsetán Aníwúrà nii

"Ikú ó ní file ẹ̀yin ṣọdẹ"

"Àrùn ó ní file ẹyin ṣọ̀dẹ̀dẹ̀"

Àwọn nǹkan aláìní èémí bí ikú, àrùn àti ọdẹdẹ níbi nii ó ti gbé ìsesí ènìyàn tàbí tí ẹlẹmi wọ wọn. Itakurosọ yìí wáyé nínú ilé Akingbade

àti nínú ọjà. Lẹ́yìn tí Ìyálóde tí ṣe kú pa Adetutu ẹrúbìnrin rẹ tí ó lóyún.

## G. **ÌFỌ̀RỌ̀DÁDÀ**

Fífi ọ̀rọ̀ dárà ní akanlo èdè ayàwòrán kan nínú èyí tí a máa ń yí ohun pò lórí ọ̀rọ̀ méjì tàbí mẹ́ta tí wọn dijọ ni sípẹ́lì kan náà tí ọkọọkan yóò wà fún wa ní ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

Yàtọ̀ sí pé ó fi ń kùn dídùn dáadáa ọ̀rọ̀ kan létí olugbọ ó tún máa ń jẹ ki a mọ òǹkọ̀tàn alatinuda àti akéwì alohùn tí ó dáńtọ́ nínú èdè. Fún àpẹẹrẹ

"Ọbàa mi máa jẹ ẹ wẹ̀wù ẹ̀tẹ́"

"Kò máa jẹ ẹ wẹ́wù ẹ̀tẹ́"

Àwọn ọ̀rọ̀ méjì tí a fi dárà ní ẹ̀tẹ́ èyí tí í ṣe orísì àrùn burúkú kan àti ẹ̀tẹ́ èyí tí a mọ̀ sí àbùkù tàbí idojuti.

## 4.1 ÀGBÉYẸ̀WÒ ÀWỌN ỌNÀ ÈDÈ INÚ FÍÌMÙ AGOGO ÈÈWỌ̀

Onírúurú ọ̀nà ni a lè gbà lo èdè. A lè lò ó lati bára ẹni sọ̀rọ̀ tàbí ìpolówó ọjà. Èyí ló mú ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola ló èdè nínú fíìmù Agogo Èèwọ̀ láti bá àwọn ènìyàn sọ̀rọ̀. Gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀tàn alátinúdá, ọ̀jọ̀gbọ́n Ishola fi ọ̀rọ̀ sì ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ láti sọ ọ̀kan-ò-jọ kan àwọn ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan láti mú kí èdè náà dùn wo tàbí dùn gbọ́.

Bákan náà ni a ń lò èdè fún orin kíkọ èyí túmọ̀ sí pé láìsí èdè orin kíkọ kò se e gbé kalẹ̀ tàbí kọ lè ní ìtumọ̀ láti àwọn tí ó ń gbọ ọ láwùjọ. Yorùbá a tún lè lò èdè láti mọ ìtumọ̀ ohun tí fere tàbí ìlú ń wí.

**A. ÒWE**

ÒWE:- Jẹ ọkan ninu ọ̀nà èdè tí ó jẹyọ nínú "fìímù Agogo Èèwọ̀" èyí tí ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola lò nínú isẹ́ rẹ yìí. Èyí wáyé nígbà tí ọba àti àwọn olóyè rẹ jọ ń sọ̀rọ̀ papọ̀ nípa ilosiwaju ìlú "Jogbo"

Fún àpẹẹrẹ:

"Ajá ìwòyí, kò ì tí mọde"

“Àgbò ìwòyí, kò ní rọ̀rọ̀ lọ́rún"

Òwe tòkè sì ìwà ìgbéraga èyí tí àwọn ìjòyè tuntun tí ọba Bọ̀sípò ṣẹ̀ṣẹ̀ fi joyè ń sọ̀rọ̀ sì olóyè Sérìkí àti Balógun nínú Ààfin. Bákan náà ni òwe mìíràn tún wáyé nínú ààfin. Fún àpẹẹrẹ:

"Àgbà ló tórò lọ, ọba lo to

"Eyín erin fọn"

Èyí túmọ̀ sí pé ẹnu àgbà ní ọ̀rọ̀ tọsi, kí í ṣe ẹnu ọmọdé.

Òwe mìíràn tún ní i

"Adìẹ ìlú Jogbo ti bà lókùn"

"Ara ò rokùn ara ò rọ adìẹ"

Èyí túmọ̀ sí pé ìlú Jogbo a nínú ìdààmú

Òwe mìíràn tún wáyé níbi tí Sérìkí, àti Balógun tí ń sọ̀rọ̀ lọ́wọ́ wí pé Bọsipo ni àwọn yóò fọwọ́ sì láti di ọba ìlú Jogbo ó ní:

"Ẹní ba má pá òkété, ojú ihò

"La máa kọ́kọ́ di"

Ìtumọ̀ èyí ni pé kàkà kí wọn fọwọ́ sì ìyàn s'óyè Arẹ́sẹ̀ Jabata, àwọn yóò yà á pá lẹ́nu mọ.

Òwe mìíràn tún wáyé nígbà tí ọba àti Ìyàwó rẹ Lápé jọ ń sọ̀rọ̀ ni pá ohun tí àwọn ará ìlú sọ pé ọba fẹ gbé tá.

"Ẹni ṣe afẹri fún aáyán

Òun náà ni ó ṣe arinako f'adiẹ"

Èyí túmọ̀ sì pe gbogbo bí ọba ṣe ń ṣe ìgbésẹ̀ láti gbé ilé-isé kan tá ni àwọn ará ìlú ń gbọ́. Èyí ló mú àwọn ará ìlú ń pè ọba ní oríṣiríṣi orúkọ bíi í

"A kò tilè ta

"Arún gún ọmọ. Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**B. Ọ̀RỌ̀ AKỌNÍ-LẸ́NU**

Èyí jẹ́ ọ̀nà isowolede nítorí pé ó máa ń jẹ ki a mọ bí ọmọdé ṣe dangajiya tó nínú ká yàrá sọ̀rọ̀. Èyí ló mú Ọjọgbọn Akinwunmi lọ isọri ọna èdè yìí níbi tí àwọn ọmọdé mẹta kan tí ń bá ara wọn sọ̀rọ̀. Fún àpẹẹrẹ.

"Ọ̀pòbọ gbọ́bọ wọ̀gbẹ́

Ó tiru ọbọ bọbọ l'ẹ́nu

Bó bá tètè gbọ́bọ wọ̀gbẹ́

Ọbọ ó gbé ọ wọ̀gbẹ̀.

**D. ỌFỌ̀**

Ọfọ̀ náà tún jẹ́ ọ̀nà isowolede tí ó wáyé nínú fiìmù" Agogo Eewọ" òǹkọ̀tàn sàmúlò èyí nínú iṣẹ́ náà. Èyí wáyé nígbà tí Latosa àti Iyalode k'ọju ìjà sí ara wọn wí pe:

"Ẹfúnsetán ìràwé ni ọ, omi lèmi

Irọ́ lo pa, ìràwé kìí tẹ̀lé omi

Òkè omi ni Irawe í wa

A jẹ́ pé mo dojuoro nù un

Ń ó sì lékè omi

Mo dòsíbàtà, n ó sì lékè odò"

Òmíràn tún jẹyọ níbi tí Ìyálóde ń fura pé oúnjẹ tí òun fẹ́ jẹ́, ní májèlé nínú. Lásìkò tí Ìyálóde fi ń pàṣẹ fún Àwẹ̀ró láti jókòó kí ó sì máa jẹ́ oúnjẹ náà. Níbi yìí ni Itawuyi tí mú àdá láti sá Ìyálóde

"Ẹfunsetan Aniwura". Fún àpẹẹrẹ :

"Dúró níbẹ̀, àgbéró ni ikú gbọ́wọ́

A-ru-nasọ ni sigidi irú ìgbà ọṣe

A kii síwọ́ lu ìmí, a kìí fesu joko

A-topo kii rọwọ họri

A-rí tá-gìrì ni tejo

Bina bá romi, a gbàgbé ilé tó fẹ jo

Wàrà wàrà lọmọdé í toko èèsì bọ̀

Aṣọ tó bá ya kìí bá abẹ́rẹ́ jìjàkadì

Jokolẹ kí ìwọ na là díẹ̀ nínú ọbẹ̀.

**E. ORIN KÍKỌ**

ORIN KÍKỌ:- Jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí òǹkọ̀tàn yìí gbà láti gbé èrò ọkàn rẹ kalnínú fìimù Agogo Eewọ yìí, láti ìbẹ̀rẹ̀ ère orí ìtàgé yìí tí de ìparí ère náà, ní onkọtan yìí tí samulo orin láti lè jẹ́ kí ohun tí ó ń sọ loorin sì. Èyí wáyé nígbà bàbà Adebayo Faleti lò nínú eré yìí. Fún àpẹẹrẹ

"Ọ̀rọ̀ lẹyẹ ń gbọ

Ọ̀rọ̀ lẹyẹ ń gbọ

Ẹyẹ ó dédé bá lorule óò

Ọ̀rọ̀ lẹyẹ ń gbọ.

Bákan náà, ní èyí tún jẹyọ níbi tí àwọn ọ̀dọ́ ìlú, tí ń fi èrò ọkàn wọn hàn fún ọba àti àwọn olóyè rẹ lórí pé wọn gba owó lọ́wọ́ wọn, wí pé wọn a tà asọ fún wọn kò ṣe èyí orin ni àwọn ọ̀dọ́ lò láti fi èrò ọkàn wọn hàn. Fún àpẹẹrẹ:

A sawo iná, a ó rii'na oo

A sanwó omi, a ó r'omi

A sanwó asọ, a ó r'asọ oo

Ọba fún wa lalaye ó ó ó. Àti bẹẹbẹẹ lọ

Orin mìíràn tún wáyé nígbà oloye Ọlọtọ àti akẹgbẹ rẹ bínú kúrò ní ààfin wí pé àwọn kò lè bá olóyè Séríkí àti Balógun jókòó papọ. Èyí ni ó mú wọn láti kó àwọn ọdọ ìlú jọ, tí wọ́n sì ń k'ọrin wí pé:

"Ìlú yìí ó lè fara rọ o

Ìlú yìí ó lè fara rọ ó o

Ẹ bá ní bẹ jọba a wá ó o

Ẹ bá ní bẹ jọba a wá ó o

Kò s'omi nílẹ̀ yìí o

Kò s'omi nílẹ̀ yìí o

Ẹ bá ní bẹ jọba a wá".

Nípa eré orí ìtàgé yìí ni òǹkọ̀tàn tún sàmúlò orin mìíràn, èyí tí ó gbé ojúṣe yìí wọ àwọn ọmọdékùnrin mẹ́ta kan wọ̀ lọrun nínú eré yìí. Fún àpẹẹrẹ:

"Kolo-kọlọ jaa

Tòwú, Tòwú oo

Kọlọ-kọlọ jaa

Tòwú, Tòwú".

Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ nínú eré yìí.

## Ẹ. ÌFỌ̀RỌ̀DÁRÀ

Èyí jẹ́ ọnà èdè ayàwòrán tí òǹkọ̀tàn yìí sàmúlò rẹ nínú eré yìí, ṣùgbọ́n èyí kò wọ́pọ̀ lọ títí nínú eré náà. Isọri ọ̀nà èdè yìí jẹyọ níbi tí Balógun àti Séríkí ń bá ọba tuntun, tí orúkọ rẹ ń jẹ Bọ̀sípò s'ọ̀rọ̀ ó ní í:

"Lafejọ sún a máa dùn àpọ́n

Kí larojo náà o wí tẹ e"

Ọ̀rọ̀ tí a fi dára nínú àyọkà òkè yìí nii: "Lafejọ àti Larojọ".

## F. ÀDÀPÈ

Èyí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn èròjà amutandun àti èyí tí ó mú ìtàn náà ṣeé wo, nítorí òǹkọ̀tàn pé àwọn ọ̀rọ̀ tí kobojumu, ya ẹlẹgẹ tàbí

tani létí ni àwùjọ sọ nínú ìtàn rẹ yìí. Èyí jẹyọ nígbà olórí ọba tí orúkọ ń jẹ Lape ń bá ọkọ rẹ sọ̀rọ̀ lórí orúkọ tí àwọn ará ìlú ń pè ọkọ rẹ̀.

"A-kó-tilé-tà"

"A-rungún" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

Ìtùmò èyí ni dípò kí wọn pe ọba ní 'ọmọ - àlè' ni wọn ṣe lo àwọn orúkọ òkè yìí láti fi pè é.

## ÀWÍTÚNWÍ GBÓLÓHÙN

Ọnà èdè yìí bákan náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí òǹkọ̀tàn sàmúlò rè nínú eré orí ìtàgé yìí èyí tí ó gbé wọ ẹ̀dá ìtàn kan tí orúkọ rẹ ń jẹ Adébáyọ̀ Fálétí nínú ìtàn yìí. Lẹ́yìn tí àwọn ìjòyè ti ṣe ìbúra. Séríkí àti Balógun lo bá ìṣẹ̀lẹ̀ làásì náà lọ. Fún àpẹẹrẹ:

Láyé Abiodun arójú iṣẹ́

Láyé Abiodun lafipa mowo

Láyé Awolẹ la di àdìkalẹ̀

Láyé Arogán-gán lafipa jọba

Nínú àṣàyàn ọ̀rọ̀ tí ó wà lókè yìí ni a lè tọ́ka "láyé Abiodun", "láyé Abiodun" ni ọ̀rọ̀ tí a ṣe àwítúnwí rẹ̀ nínú gbólóhùn yìí àti 'láyé' gẹ́gẹ́ bíi àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀.

## ORÍ KARÙN-ÚN

### 5.0 ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀

Àgbéyẹ̀wò Ètò Òṣèlú Nínú Eré Oníṣe"Ẹfunsetan Aniwura" àti Eré Onise "Agogo Eewọ" tí ọjọgbọn Akinwunmi Ishola kọ ní ọdún 2002, ní ìṣe àpilẹ̀kọ yìí dálè lórí. Ní orí kín-ín-ní lábẹ́ ìfáàrà lórí ìṣe ni mo ti mẹ́nuba bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ sílẹ̀ àti onírúurú akitiyan tí àwọn ènìyàn tí ṣe pẹ̀lú ọdún tí àwọn ènìyàn wọ̀nyí ṣe iṣẹ́ náà ni ọkọ̀ọ̀kan, mo sì tún mẹnuba bí ìwé ère orí ìtàgé ṣe bẹ̀rẹ̀ àti ìdàgbàsókè rẹ. Níbi ni mo ti sọ̀rọ̀ lórí ipa tí eégún Alárè kò àti onírúurú àwọn osere mìíràn nípa àti wáyé eré orí ìtàgé.

Ní ìparí orí Kìn-ín-ní mo ti tẹ̀síwájú láti ṣàlàyé lórí àpẹẹrẹ ìwé àti òǹkòwé oníse lorisirisi nínú èyí ni mo ti sàfihàn akitiyan àwọn òǹkòwé, àkọ́lé ìwé tí wọn kọ pẹ̀lú ọdún tí wọn gbe é jáde.

Ní orí kejì iṣẹ́ àpilẹ̀kọ mi ni mo ti tú kẹ̀ẹ̀kẹ́ ọ̀rọ̀ nípa fíìmù "Agogo Èèwọ̀" gẹ́gẹ́ bí eré àgbéléwò tí ó kóni l'ọgbọn lorisirisi nípa ètò òṣèlú. Mo tẹsiwaju láti ṣe àgbéyẹ̀wò ètò òṣèlú inú fíìmù àgbéléwò náà pẹ̀lú àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ó wà nínú eré àgbéléwò yìí, èyí kò mọ bẹ́ẹ̀, ìgbìyànjú tún tẹ̀síwájú lórí àhunpọ ìtàn inú eré náà. Bákan náà ni àpèjúwe àwọn ẹ̀dá ìtàn inú fíìmù náà kò gbẹ́yìn nínú orí kejì iṣẹ́ àpilẹ̀kọ mi yìí.

Orí kẹta ni mo ti sàlàyé nípa eré oníse "Ẹfúnsetán Aníwúrà" nínú èyí ni mo ti sọ̀rọ̀ lórí ètò òsèlú inú ìtàn naa; nítorí pé 'Ẹfúnsetán Aníwúrà' jẹ́ akíkanjú obìnrin ni ìlú Ibadan tí ó sì ní ẹrú tí

ó pọ. Mo tẹ̀síwájú nínú èyí tí mo tọ́ka sí àwọn kókó inú ìwé ìtàn náà, mo tún ṣe iṣẹ́ lórí ahunpọ ìtàn náà láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin ìtàn náà.

Ní orí kẹta isẹ yìí ní mo ti sọ̀rọ̀ lórí àpèjúwe àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ère onise yìí, nínú èyí ni mo ti sọ̀rọ̀ lórí ìwà àti ìse sì wọn tí onkọtan gbé wọ̀ wọn l'ọrun gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn náà.

Ní orí kẹrin ni àlàyé tí wáyé lori ìlò èdè inú ère onise "Ẹfúnsetán Aníwúrà" àti ohun tí ìlò èdè gan-an túmọ̀ sí. Bákan náà ni mo tún wo ìlò èdè inú fíìmù àgbéléwò "Agogo Eewọ" nínú isẹ àpilẹ̀kọ yìí. Ní itẹsiwaju ni mo ti sàlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ àwọn ọ̀nà isowolo èdè inú àwọn ère wọ̀nyí "Ẹfúnsetán Aníwúrà" àti "Agogo Eewọ"

## 5.1 ABÁ ÀTI ÌṢÒRO TÍ Ó KOJÚ OLÙWÁDÌÍ

Mo dá laba fún ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ àpilẹ̀kọ rẹ lórí Eto Oselu inú ère orí ìtàgé àgbéléwò tàbí ìwé eré onise kan, ní láti ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ sùúrù, láti lè mọ àwọn kókó tótọ́ láti lè ṣe iṣẹ́ lè nínú eré náà. Tí Kò bá ní yín àgbàdo rẹ sẹ́yìn ìgbà lásán.

Onírúurú laṣọ alágẹmọ bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọ̀kan-ò-jọkan ìṣòro tí ó dojú kọ ìṣe àpilẹ̀kọ mi yìí ríi.

Lakọkọ ìṣòro iná mọn-na-mọn-na jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lórí ìṣe yìí láti lè wọ erè orí ìtàgé yìí. Èkejì tún ní ìṣòro owó náà kó gbẹyin nínú ìṣe àpilẹ̀kọ yìí. Ṣùgbọ́n mo dúpẹ́ lọwọ Ọlọ́run Olódùmarè tí ó jẹ ki n borí

ìṣòro yìí nípa bí ọgọrọ àwọn ènìyàn ṣe ń fi mí l'ọkan bálẹ lórí àṣeyọrí ìṣe àpilèkọ yìí.

Bákan náà, mo tún ní ìṣòro nípa àkókò nínú èyí tí ó jẹ wí pé nígbà miran ti mo ba gbìyànjú láti rí pé àwọn ẹri ti yẹ kín wo nínú eré yìí, ní àwọn òṣìṣẹ́ oni-na-mọn-na-mọn-na máa ń ṣe seke-seke nígbà náà. Ọpẹlọpẹ alabagbe mi ti o ni èrò tí ó máa ń mú iná wá ní o se okùnfà ọ̀nà àbáyọ sì ìṣòro náà.

## 5.3 ÌKÁDÌÍ

Kò sí àní-àní pé ipa ọ̀jọ̀gbọ́n Akinwunmi Ishola nínú kíkọ ìtàn Yorùbá kò ṣe fọwọ́ ro s'ẹyin nítorí kété tí àwọn ere orí ìtàgé wonyi jáde ní o ti di ìtẹ́wọ́ gbà láàárín àwùjọ àwọn Yorùbá káàkiri orílẹ̀-èdè agbalaaye yìí.

Bákan náà ni ìtàn eré orí ìtàgé yìí "Ẹfunsetan Aniwura" àti Agogo Eewọ" kò ipa pàtàkì lórí bí ènìyàn ṣe ni lati jẹ́ olootitọ láàárín Ìlú tàbí fún ẹni tí ó bá wà ní ipò olórí.

## ÌWÉ ITỌKASI


Adésọ̀kàan, A. "Bawo ni Wọn ṣe rii: Iselu ati Ẹwa ti Awọn fiimu Fidio Naijiria", satunkọ nipa John Conteh-Morgan and Tejumola Olaniyan, 189-197. Bloomington: Indiana University Press. 2004.

Adú, O.T. "Àwọn ọ̀rọ̀ ìpolongo ní Yorùbá Fidio Films". Ti ko tẹjade M.A Project, University of Ìbàdàn (Nigeria). 2009.

Akinwunmi Ishola (1968) Ẹfunsetan Aniwura, Oxford University Press 1970 Reprinted 1972 (twice) 1973, 1974, 1977, 1984, 1992, 2001, 2003.

Akinwunmi Ishola (2002) Agogo Èèwọ̀,

Akínyẹmí, A. "Litireso ẹnu, Ẹwa, Gbigbe ati Iwoye Awujọ ni Fidio Yorùbá Meji, Awọn fiimu" Iwadi ni Awọn Litireso Afirika 38, no 3, 122-135. 2007.

Àlàmú, O.O. Awọn oran ati Awọn italaya. Lasu Iwe akosile ti Awọn ẹkọ Afirika. 15. 2012

Àlàmú, O.O. "Trends in the Development of Yorùbá Film: The First Ewadun (1976-1986)",

Àlàmú, O.O. Awo ise ninu Yorùbá Fidio Films. Ile-iṣẹ Iwadi fun Awọn ede Agbaye. Japan. 2010.

Armes, R. "Ṣiṣe fiimu Afirika: Ariwa ati Gusu ti Sahara. Bloomington: Indiana, University Press. 2006.

Arúlógun, A. "Ipa ti Fiimu ni idanimọ aṣa ni Opubor and Muneh (eds) Idagbasoke ati Idagbasoke ni Ile-iṣẹ Fiimu ni Nigeria, Lagos: National Council for Arts and Culture. 2009.

AWONIYI T. A (1974) Ìwé Atumọ Ede, Chambers.

D.O Fagunwa (1938) Ifaara si litireso Naijiria

Mainframes Production

Mobolaji, W.A. "Ìhà tí Fágúnwà Kọ Sí Ètò Ìdájọ́ Ní Àwùjọ Yorùbá" nínú Ọ̀tun Ìmọ̀ nínú Ìtàn Àròsọ D.O Fágúnwà. Lagos: The Capstone Publications. 2016.

Musikawong, S. "Awọn iṣe Ṣiṣẹ ni iṣelọpọ fiimu olominira Thai ati pinpin. Inter Asia Cultural Studies, vol 8. 2007.

Ogundeji, P.A. and Fasehun, M. A. "Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti Àsọtẹ́lẹ̀ Nínu Àsọdàsílẹ̀ D.O Fágúnwà" nínú Ọ̀tun Ìmọ̀ nínú Ìtàn Àròsọ D.O Fágúnwà. Lagos: The Capstone Publications. 2016

Olújìnmí, I.O. "Awọn aworan ti obinrin ni Yorùbá Fidio Films". Unpublished Ph.D Thesis, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn. (Nigeria) 2005.

Olúkojú, E.O. “Ibi ti orin ni Yorùbá Ibile ati Litireso Alohun” Unpublished Ph.D Thesis University of Ìbàdàn, Ìbàdàn. (Nigeria) 1978.

Yekeen, T. “Lilo awọn itan-akọọlẹ ni awọn fiimu Yorùbá”. Ti a ko tẹjade MA ise iwadii Ile eko giga ti Ìbàdàn, Ìbàdàn (Nigeria) 2009.

Yusuf, A.R. “Adébáyọ̀ Fálétí on Screen”.Unpublished M.A Project University of Ìbàdàn, Ìbàdàn (Nigeria) 2006.